Híhá Ni Ẹnu Ọ̀nà Náà

O ṣeun, Arakunrin Neville. O ṣeun. O dara pupọ lati pada sinu Ile Oluwa. Mo maa n gbadun ati pada sinu ile-ijọsin yii, ibi yoowu ti mo lọ. Nkankan wà nipa ibi kekere yii ti mo fẹran lati maa pada wa sibẹ. O ṣaa jẹ, ah, mo…Òun nikan ni ìjọ mi àkókó ti mo jẹ oluṣọ-aguntan fun. O si dabi ẹni wipe o dara lati tun pada wa sibi yii. Mo si gbagbọ wipe ni owurọ ọjọ́ nla naa, nigbati òòrùn ba kọ̀ lati ràn, ti awọn irawọ si ti mu imọlẹ wọn kuro, mo gbagbọ wipe awọn kan wà ninu ile-ijọsin yii, ti wọn yoo wà nibẹ lọjọ́ naa, awọn ti a ti wẹ̀ ninu Ẹjẹ Ọdọ-aguntan. Emi n foju sọna fun akoko yẹn.

2 Bi mo ṣe n bọ̀ lati inu yara nisisiyi, mo pade Arabinrin Arganbright lẹyin nibẹyẹn. O n sọ fun mi wipe awọn eniyan kan wà nibi yii, ti wọn wà nibi ipade Kingston, awọn ti wọn bẹ̀ wá wò nigbayẹn, mo si…ti…inu mi dun pupọ lati ni wọn nibi yii gẹgẹbi èrí. Ibi yoowu ti wọn wà, ti wọn ba lee na ọwọ́ wọn soke, ẹyin ti ẹ wà nibi ipade Kingston ni Jamaica. Bẹẹni, wọn wà ni ẹyin. Ko buru, iyẹn dara bẹẹ.

3 Mo ri iwe-ipe ti Oral. Mo lero wipe ẹ ti ṣe ikede awọn ipade rẹ̀. Emi ko mọ awọn ọjọ́ naa, ayafi àná. Mo ro wipe ọjọ́ kẹfà ni o bẹ̀rẹ̀, tabi bẹ́ẹ̀kọ́? Ọjọ́ kẹfa titi de ọjọ́ kẹẹdogun, Arakunrin Roberts yoo wà ní Louisville. Ni bayi, ẹ lọ gbọ iwaasu rẹ̀. Arakunrin Roberts jẹ—òrẹ́minú temi, iranṣẹ Kristi tootọ si ni. O da mi loju wipe ẹ o gbadun awọn iwaasu rẹ, ni alaalẹ́. O jẹ…tirẹ̀, bi oun ṣe n gbadura fun awọn alaisan, mo—o da mi loju wipe ẹ o ri iṣẹ́ Ọlọrun, nitoripe jagunjagun igbagbọ nla ni, iyẹn Arakunrin Roberts, ẹniti Ọlọrun n lo gidigidi ni. Iṣẹ́-iriju iwaasu rẹ̀ sì bẹ̀rẹ̀ lati…

4 Mo ranti igba ti mo kọ́kọ́ pade Arakunrin Roberts, o wà labẹ àgọ́ kekere kan ti o ti fàya ni St. Louis, Missouri, emi si…rara, ni Kansas City, Missouri ni. Emi si wà ní Kansas City, ni Kansas, ninu gbọ̀ngàn kan. Oun joko si iwaju. Lẹyin ti isin pari, a lọ si ẹyin, a si jọ n sọrọ. Wọn fi emi han oun. O kere si mi ni ọjọ́ ori; Oral ṣẹ̀ṣẹ̀ lé ní ogoji ọdun ni. O si wipe, “Ṣe o ro wipe Ọlọrun yoo gbọ adura mi fun awọn alaisan?”

Mo ni, “Arakunrin, Oun yoo gbọ adura ẹnikẹni ti ó bá gbadura.” Ó bẹ̀rẹ̀, ó si wipe, “Mo ti bẹrẹ niyẹn!”

5 Ẹnikan ti o jafafa ni, o jade ile-iwe giga, ọdun mẹrin ni o fi kẹkọ nipa ihuwasi eniyan, o si da mi loju wipe o jẹ—o jẹ ọlọpọlọ pipe. O ti dé ibikan bayi, ti o jẹ wipe o fi awọn onímọ̀ràn yí ara rẹ ká, ati

awọn nkan, tobẹẹ ti o jẹ wipe, nigbati o ba sọrọ, o—o maa n ronu jade sita. Ẹ o si gbadun rẹ gan-an ni, o da mi loju.

6 Njẹ ni bayi, mo fẹ fun yin ni iroyin diẹ nipa ohun ti Oluwa wa ṣe ninu ipade wa kekere ni Jamaica ati ni Puerto Rico. Ohun ajeji ni wipe mo lọ sibẹ, nitori ọpọlọpọ ìpè ni o wọlé. Gẹgẹbi Leo ṣe mọ, wipe èrọ ibanisọrọ…Ni aarin ọsẹ kanṣoṣo, ọgọọgọrun ni awọn ti o pè fun ipade. Ṣugbọn sibẹ, mo maa n fẹ ki a dari mi si ibiti emi yoo lọ, mo fẹ bẹẹ. Ti mo ba lọ nitoripe ẹnikan pe mi wipe ki n wa, a jẹ wipe mo lọ ni orukọ ijọ yẹn tabi ìpéjọpọ̀ yẹn. Ti mo ba lọ nitoripe Arakunrin Neville sọ pe ki n lọ, mo nilati lọ ni orukọ Arakunrin Neville. Ṣugbọn emi n fẹ lati lọ nigbati Jesu ba ran mi, ki a lee lọ ni Orukọ Jesu Oluwa, lati ba awọn eniyan pade.

7 Mo dùbúlẹ̀ sori ibusun, o rẹ mi diẹ. Ni afonifoji yii, laipẹ laijina, mo nilati fi afonifoji yii silẹ, nitoripe o n mu ọ̀fun dun mi tobẹẹ ti ara mi ko fẹ gba a mọ. Mo lee lọ, ki n tun pada wa…Nigbati a de ni ijelo, emi ati Leo, laarin ogoji maili, lẹyin ti a wà níbi àkùrò ni Florida, ọ̀fun mi mọ́, ṣugbọn laarin ogoji maili si Louisville, o tun dáwọ́ duro. O yẹ ki Arakunrin Banks Wood wa nibi ni owurọ yii. Ni ijelo ti a n bọ lati Kingston ati—ati Puerto Rico, nibiti ọ̀fun mi ti duro daradara; mo sọkalẹ kuro ninu ọkọ̀ ofuurufu, ara mi ya gaga sibẹ; ṣugbọn ki a to de Jeffersonville, o tun ti dí pada. Afonifoji yii lo fa a. Awọn kokoro inu afẹfẹ ni, boya Ọlọrun si ni, ọkan ninu wọn, ni o fẹ mu mi kuro. Nitorinaa, emi—kò yé mi. Mo ti gbadura, mo si ti beere ni ọpọlọpọ igba.

8 Ṣugbọn mo ṣẹ̀ṣẹ̀ jí ni, ni nkan bii agogo mẹta òru. Iyawo mi ati ọmọkunrin mi kekere ti sun lọ. Mo dide joko ni ẹ̀gbẹ́ ibusun, mo si ri ọpọlọpọ eniyan ti wọn pejọ si ibikan ti o fẹ̀, mo sọ fun Billy Paul wipe, “Wọ inu ibẹyẹn lọ, ki o si fun awọn eniyan wọnyẹn ni kaadi adura.”

9 Oun si wipe, “Ko buburu, baba mi.” Ni iṣẹju melo kan, o pada, o si wipe, “Iwọ kò lee fun awọn eniyan wọnyẹn ni kaadi adura.” O ni, “Ṣe o ri ọkunrin ti o duro sibi yii?”

Mo ni, “Bẹẹni.”

10 O ni, “Ó wá sibi yii, mo si wipe, ‘Gbogbo eyin ti ẹ nilo kaadi adura, ẹ na ọwọ yin soke.’” O ni, “Mo lọ lati fun-un ni kaadi adura, oun si gba ibomiran lọ. Mo si tun lọ sibẹ, o tun lọ si ibomiran. Ni bayi, oun niyi nibi yii.” O ni, “Emi ko tilẹ lee pin kaadi adura eyọkan.”

11 Mo ni, “Ko buru, Billy, o ko nilo lati pin kaadi adura, nitoripe aaye ti o wa nibi yii fẹ tobẹẹ ti olukuluku eniyan lee…” Kaadi adura wà fun ati dènà idarudapọ…ṣe o ye ọ, lati mu ki wọn wa leto.” Mo ni, “Mo lee kó gbogbo awọn eniyan ti o wa nibẹyẹn, iye awọn ti ó bá

lee kún aaye ti mo ni, ki n tò wọ́n sori ila, ki n si gbadura fun wọn ni ẹyọ kọọkan."

12 Oun si wipe, "Ko buru." O kọju si apa ọtun, o si kuro lọdọ mi. Emi kọju si ibi *yii*, bi oun ṣe gba ọna *yẹn* lọ, mo si n wo o.

13 Mo si gbọ ti Ohùn kan sọkalẹ lati Ọ̀run wá, Ó ní, "Ṣugbọn ni akoko yii, Emi yoo bẹ̀rẹ̀ si gbe ọ ga." Mo wò, emi ko si ri ọpọ ero ti ó tó bẹyẹn ri, nṣe ni wọn n rọ́ wá lati ibi gbogbo.

14 A pe orukọ Arakunrin Roberts, wipe, "Ni bayi, Arakunrin Oral Roberts n bọ wa ri ọ."

Mo si wipe, "Bawo ni n o ṣe kí Arakunrin Roberts?"

O ni, "Gẹgẹbi oun naa ba ṣe ki ọ ni."

15 Mo ri Arakunrin Roberts ti o n bọ pẹlu kóòtù dudu lọrun, pẹlu fila kekere kan bi eyiti Bing Crosby maa n dé, awọn fila ti wọn maa n yi soke, ti wọn yoo tun fa a wa silẹ, fila dudu kekere kan ni. Emi duro sori oke kan, oun wo oke, o si wipe, "Pẹlẹ o, Arakunrin Branham."

Mo si wipe, "Pẹlẹ o, Arakunrin Roberts," mo bọ́ ọ́ lọwọ.

Ó sọ pe, "O ní èrò pupọ daradara."

16 Mo ni, "Èrò pupọ ni, Arakunrin Roberts." O pẹyinda, o si lọ bi Billy ṣe lọ, si apa ọtun.

17 Mo ronu pe, "Ibo ni n o duro si lati ba wọn sọrọ?" Mo gbiyanju ibigbogbo lati wá ibikan ti mo ti lee ba wọn sọrọ. Mo wà ni ipo kan, nkankan wà ni isalẹ, tobẹẹ ti n ko ri ibi ti mo ti lee—ti lee ba wọn sọrọ.

Ẹnikan si sọ pe, "O dara, maa bọ nibi yii."

18 Mo ni, "O dara, ṣugbọn eniyan ko lee riran nibẹyẹn daradara." Mo gbera lati lọ si ọna ibẹ. Mo ranti eyi nigbanaa, mo wipe, "Ohun ti o ṣe kókó fun mi lati ṣe ni wipe ki n jẹ onirẹlẹ ninu ọkan mi nigbagbogbo, niwaju Ọlọrun ati awọn ọmọ Rẹ̀."

19 Mo si kuro ninu iran naa. Mo wá ronu pe, "Kini iyẹn tumọ si? Boya o tumọ si wipe a o ni iru nkan…Tabi nibo ni—nibo ni yoo ti ṣẹlẹ?" Njẹ ẹ mọ, nigbamiran ninu iran, Oun ki yoo sọ ibẹ fun ọ, Oun—Oun yoo sọrọ, iwọ yoo si…Bi òwe ni. O si da mi loju wipe o ye ẹyin ti ẹ maa n ka Bibeli.

20 Mo lọ si iyara iwaju, mo si joko fun igba diẹ, o si ti n lọ si bii agogo mẹta-aabọ tabi mẹrin òru. Oorun wa n kun mi gidigidi. Mo pada lọ dùbúlẹ̀, mo si la ala kan, o si jẹ ala ti o yatọ patapata. Ọpọlọpọ yin ni o mọ ọkan ninu awọn alakoso mi, Jack Moore. Arakunrin Jack Moore, mo ti mọ ọ fun ọpọlọpọ ọdun. Mo ro wipe emi ati ọmọbinrin rẹ jọ jade lọ, ọmọbinrin bii ọmọ ọdun mẹtadinlogun, mo fa a lọwọ,

mo n mu u lọ sori oke kan, Jackie kékeré. Lati igba ti o ti wà ni ọmọ ọmú ni mo ti mọ ọ. Mo si n mu u lọ sori oke kan, mo rin irin bii ilé mẹta si ori oke naa, mo n mu ọmọdebinrin yii lọ. A de abẹ igi nla kan, oun si joko. Gẹgẹbi ọpọlọpọ awọn ọdọbinrin ode oni ṣe maa n wọ awọn yẹrì ti o fẹ, oun wọ ọkan ninu iru awọn yẹrì yẹn. O wa mu yẹri yii, o tẹ ẹ silẹ, o si joko. Gẹgẹbi awọn ọdọ ṣe maa n wo ara wọn, o ká ọwọ rẹ kò bayi, o si bẹrẹ si wo oju ọrun. Jackie jẹ ọmọbinrin kan ti o rẹwa, ṣugbọn o ni ẹnu ati oju ti o tobi, irun ori rẹ si pọ́n rẹ́súrẹ́sú, kò fani mọra pupọ, ṣugbọn ọmọbinrin gidi ni. Mo ri oju rẹ ti o tobi, nigbati o wo oju ọ̀run, oju ọ̀run si tan imọlẹ si oju rẹ.

21 Mo kuro lọdọ rẹ fun bii ẹsẹ̀ bata marun, mo si fi ẹ̀gbẹ́ kan lélẹ̀ bi *eleyi*, mo mu ìsẹ́pẹ́ igi kan, mo fi si ẹnu mi, mo si n jẹ ìsẹ́pẹ́ igi yii. Mo si bẹrẹ si ronu wipe, “Kini mo n ṣe loke ibi yii? Eeṣe, emi baba arugbo, pẹlu ọdọmọbinrin yii. Mo ni, “Eeṣe, mo ti ni iyawo, mo si ti bi awọn ọmọ. Emi ko ni nkankan ṣe nibi yii pẹlu ọdọmọbinrin yii.”

22 Mo mura lati dide. Nigbati mo ṣe bẹẹ, Ohùn kan jade wa lati inu igi naa, o si wipe, “Eyi wa fun ami, ati fun idi kan.”

23 Mo ji, mo si fẹrẹ pariwo—alakala ni. Mo ronu wipe, “Ah, iyẹn ha tumọ si wipe emi yoo pada seyin ni, tabi nkankan yoo ṣẹlẹ si mi?” Mo ronu wipe, “Ti mo ba gbiyanju lati lo èrò ọkan temi, gbogbo rẹ yoo daru mọ mi loju, nitorinaa, emi yoo duro de Ọlọrun.” Mo si bẹrẹ si gbadura. Mo ni, “Oluwa, ṣe àlá yẹn nii ṣe pẹlu iran ọ̀gànjọ́ oru yẹn, tabi kini o tumọ si?”

24 Lẹyin ti mo duro fun igba diẹ, boya wakati kan (Iyawo mi ti dide, o si ti ṣe ounjẹ owurọ tan.), Ohùn naa si tun pada wa, o wipe, “Maa lọ si Kingston, a o si sọ ohun ti iwọ yoo ṣe fun ọ nibẹ.”

25 Nitorinaa, lẹsẹkẹsẹ, mo lọ si Kingston. Wọn si—wọn si ti mọ̀ ní ọ̀sán Ọjọ́bọ̀ wipe n o wà nibẹ ni Ọjọ́ Ẹtì. Gbogbo ikede ti a ní niyẹn. Emi ko mọ bi a ti n ṣe…?…tabi bi a ṣe n daba bi èrò ṣe pọ̀ sí, nitoripe mo maa n sabaa fi kun-un ni. Ṣugbọn ni alẹ́ àkókọ́, mo lee sọ wipe a ni to bii mejila, ani bii ẹgbẹfa eniyan, nita, nitoripe ọjọ́ kanṣoṣo ni wọn fi mọ̀. Ni ọjọ́ keji, wọn gbe awọn eniyan dide, ti wọn sare fun maili mẹrin, ere ije, lọ si awọn ori oke. Ẹnikan yoo sare fun wakati mẹrin, lẹyinnaa, wọn yoo jẹ ki ẹlomiran sare lọ sori oke. Ni alẹ ọjọ́ keji, wọn to bii ẹgbẹrun marun. Ni alẹ ọjọ́ kẹta, wọn to bii ẹgbẹrun mẹẹdogun, tabi ogun. Ẹgbẹẹgbẹrun ni awọn ti o wa sọdọ Oluwa.

26 Ìran naa ni ijọ kekere yẹn, ọmọbinrin yẹn jẹ wundia, ọmọde si ni, iyẹn si tumọ si wipe ijọ yẹn jẹ wundia. Awọn ilé mẹta titi de ori oke yẹn, ni ọjọ́ mẹta ti emi yoo fi waasu. N o si mu ijọ kekere naa ti o jẹ wundia nipa iṣẹ-iriju iwaasu mi, kuro nibiti o wà, lọ sibi giga ninu awọn nkan ti Ọlọrun, tobẹẹ ti o mi gbogbo agbegbe naa.

27 Ah, awọn oniwaasu ati awọn eniyan ti o wa ni ayika naa n kigbe, wọn n bẹbẹ, wọn n rọ wá wipe, “Ẹ fun wa ni alẹ ọjọ́ kan tabi meji si i,” awọn adari ilu naa sọ bẹẹ.

28 A gba ibẹ lọ si Puerto Rico. Nibẹ, a ni iṣẹgun nla, ẹgbẹẹgbẹrun awọn eniyan ni o wá sori papa naa, tobẹẹ ti wọn sọ wipe bii ẹgbẹrun lọna ogoji ọkàn ni o wa sodọ Jesu Oluwa. Nigbati a fẹ kuro nibẹ, mo nireti wipe emi…emi yoo sọ eyi fun ijọ temi, ṣugbọn n ko lee ṣe bẹẹ ni ita, nibiti ko ti si awọn ara ilé, nitoripe wọn lee tumọ rẹ si òdì. Ṣugbọn mo ni orukọ adajọ naa lori tákàdá nibi yii, ẹniti o sọrọ nigbati a fẹ kuro, nibi yii, oun ati awọn alabaṣiṣẹpọ rẹ.

29 Mo si…Oun—o ni, “A da wa lọla ni erekusu yii lati ni oniruuru awọn oniwaasu.” O ni, “Ọgbẹni Billy Graham ṣẹ̀ṣẹ̀ kuro ni erekusu yii laipẹ yii ni,” o ni, “a ni—ipade ologo,” o ni, “ṣugbọn Ihinrere ti a ti n gbọ tẹ̀lẹ̀ naa ni Billy Graham mu tọ wá wá.” O ni, “Lẹyinnaa, a da wa lọla lati ni Ọgbẹni Roberts ni erekusu yii,” o ni, “Ọgbẹni Roberts si fun wa ni ipade ọlọ́jọ́ mẹta ti o lagbara. Ṣugbọn” o ni, “owó ti a na sori ile-itura pọ pupọ,” o ni, “egbẹrun marundinlogoji dọla ni o na wa fun ọjọ́ mẹta naa, lati gba ile-itura.” O ni, “Lẹyinnaa, Ọgbẹni Osborn wa sibi, ẹniti i ṣe iranṣẹ nla fun Kristi. Ṣugbọn,” o ni, “nigbati Ọgbẹni Osborn lọ tan, ijakulẹ wà,” o ni, “o dabi ẹni wipe ohun gbogbo ti lọ.”

30 O ni, “Ṣugbọn a ṣe akiyesi ninu ipade eleyi, wipe o fẹrẹ má si ẹnikẹni lori pẹpẹ fun Arakunrin Branham lati gbadura fun. Ṣugbọn,” o ni, “lẹyin ti awọn ìsìn naa pari, ọpọlọpọ ẹ̀kún ọkọ̀ awọn aga ati òpá-ìrìnsẹ̀ ni a kó jọ, laarin awọn ijọ eniyan.” O ni, “Ni asiko yii, ki i ṣe eniyan, Ọlọrun ni o tọ wá wá,” ni o sọ.

31 Mo ni, “Ẹ maṣe reti adura temi; bikoṣe adura tiyin nibẹyẹn, ẹ gbe ọwọ yin le ara yin.” Wọn lee ko eniyan bii mejila tabi mẹrinlelogun wa sori pẹpẹ, nigbati imọ-ẹmi-yatọ ba si sọkalẹ wá, awọn eniyan naa yoo kan pariwo ni. Ile-itura olowo poọku ni a de si, awa ni a si san gbogbo owo ti a na funra wa.

32 Ẹyin ni ẹ ran wa lọwọ lati ṣe iyẹn, nipa awọn idamẹwa yin ti ẹ n fi ranṣẹ si mi. Ohun ti ó ṣe é niyẹn. Mo si fẹ ki ẹ mọ wipe, ninu gbogbo awọn nkan wọnyẹn, ẹ ni ipin ninu rẹ. Ni ọjọ́ ologo nla naa ti o n bọ, Ọlọrun yoo fun yin ni èrè fun iyẹn. Ṣe ẹ mọ, ẹ ko ni…

33 Ti ẹnikan ba lọ funra rẹ, ti o si ṣe nkankan, njẹ ẹ mọ, nigbati ẹni yẹn ba lọ tan, wọn yoo ronu pe, “Ijakulẹ nla ni, Ọlọrun ti fi wa silẹ.” Ọlọrun ko fi yin silẹ. O wà pẹlu yin nigbagbogbo. Ṣe ẹ mọ, o…Ẹyin naa ní ipin ninu rẹ gẹgẹbi ẹnikẹni. Ọlọrun lee lo ẹnikan fun iṣẹ-iriju kan pàtó, ṣugbọn iyẹn ko sọ wipe ẹni yẹn ni aṣẹ lori Ọlọrun. Igbagbọ tiyin ninu Ọlọrun ni.

34 Wọn yoo jade lọ ninu awọn ọmọlanke kekere kan, wọn yoo mu awọn ẹsẹ ọkọ ọmọde kan, wọn—wọn yoo si gbẹ pako pẹlẹbẹ kan, wọn yoo gbe awọn eniyan sori rẹ, wọn yoo si yí wọn wọle. Lẹyin ti isin ba si ti pari, ti gbogbo papa iṣere naa ti dá, wọn yoo lọ pẹlu awọn ọkọ, wọn yoo si ko gbogbo awọn ọmọlanke wọnyẹn, pẹlu awọn aga, ati òpá, ati ibusun ọmọde ati ti agba, eyiti awọn eniyan ti fi ẹsẹ wọn rin kuro ninu rẹ, ti wọn si fi silẹ, nitoripe Iwalaaye Oluwa wà nibẹ. Ohun ti a fẹ ri niyẹn. Eniyan ko sí loju agbo mọ nigbayẹn, Ọlọrun ni o n ṣiṣẹ.

35 Mo pada wá, lati ṣe iranlọwọ diẹ ni owuro yii, emi yoo sọrọ fun iṣẹju diẹ. Mo sọ fun awọn ọmọkunrin naa wipe ki wọn maṣe jọwọ́ ohùn ti a ká silẹ. Ọjọ́ mẹta ni mo fi ronu gidigidi wipe, “Kini n o sọrọ le lori?” Owuro yii, ki n to kuro, mo ni imọlara gidi ninu ọkan mi lati kilọ fun ijọ. Mo sọ fun wọn wipe, “Ẹ ká awọn ohùn naa silẹ, ṣugbọn ẹ maṣe jọwọ́ wọn fun tita.”

36 Ṣugbọn ki a to ṣe eyi, mo fẹ lati fun yin ni ẹri kekere kan, ki o lee ṣe yin ni rere. O ṣe emi ni rere. A lọ si irin-ajo ọjọ́ mẹta kan lati pa ẹja, Leo, Gene ati emi, ọmọ mi, Billy Paul ati iyawo rẹ, si ọdọ ọrẹ wa kan ti o maa n wa si ile-ijọsin nibi, lati ilu Georgia. Wọn mu wa lọ si àkùrọ̀ kan, emi ko mọ ibiti o wà bayi, nitosi Okeechobee tabi nkankan bẹyẹn, n ko mọ orukọ ti awọn Seminole India n pe e. Ṣugbọn ọpọlọpọ maili ni a fi jinna si igboro.

37 Arakunrin Evans yii, ẹlẹsẹ̀ ni ẹgbọn rẹ. Apẹja nla kan ni oun, o si lọ sibi àkùrọ̀ ni oṣù melo kan seyin. Wọn si ni ejo kan nibẹ ti wọn n pe ni “paramọlẹ.” Paramọlẹ yii bu u jẹ, tipatipa ni o si fi ru u là. Ẹsẹ̀ rẹ wú, wọn si gbe e lọ sọdọ awọn dokita, wọn fun-un ni abẹ́rẹ́. Aṣekupani ni awọn ejo wọnyẹn. Wọn ni ọpọlọpọ ejo sèbé nibẹ pẹlu, sèbé, mọ́námọ́ná, ati ọ̀ọ̀nì ti o gun to ogun ẹsẹ̀ bata.

38 Bi a ṣe n pẹja lọwọ nibẹ, ìwọ̀ mi gbe ẹja nla kan. Ah, o jẹ́ ọjọ́—ọjọ́ itura gidi. O tobi tobẹẹ ti n ko lee gbe e jade kuro ninu odò, o na ìwọ̀ mi, o si yọ ara rẹ jade. Ọpọlọpọ ẹja nla ni o wà nibẹ, ẹja nla ti o wọ̀n to bii aadọjọ́ ìwọ̀n. Awọn ẹja naa, awọn kan ninu wọn to ọpọlọpọ ìwọ̀n, ìwọ̀n bii mẹrin si meje, tabi mẹjọ. Mo gbe ẹja nla yii, o si yọ kuro.

39 Mo tun sọ ìwọ̀ mi si odò, mo si—mo gbe omiran, bii iwọn mẹfa si meje. Ọpa ìwọ̀ ẹja mi gun tobẹẹ ti mo nilati naa soke ga ju awọn ewé oju omi lọ. Arakunrin Evans si ti…Ara gbogbo wa ti tutu, nibiti a ti n rin ninu omi, nitoripe àkùrọ̀ ni gbogbo ibẹ. Oun ti bọ́ bata rẹ, o si ti ká sokoto rẹ soke, o si joko si ibikan ti o gbẹ, o n sa aṣọ rẹ ki o lee gbẹ. O wa ri ẹja nla yii ti o n yi kiri ninu igbo, emi si n la inu omi kọja lọ si ọdọ rẹ. O ni, “Duro na, Arakunrin Branham, emi yoo ba ọ mu u.” O sare lọ sibẹ. Mo ti fa a soke, mo si ro wipe ẹja naa ti

fẹ́ kú, nitoriti o duro sori ewe oju omi. Oun si sare lọ sibẹ lati mu u. Nigbati o ṣe bẹẹ, o pariwo, o si pada wa. Paramọlẹ kan ti bu u jẹ.

40 A wo o, oju ẹyín ejò naa wa ni ẹsẹ̀ rẹ, nibiti paramọlẹ naa ti bu u jẹ, o si n dun-un tobẹẹ ti omije n jade loju rẹ. O ni o dabi ẹni wipe egungun oun ti fẹ gan. A wa nibẹ, ni ọpọlọpọ maili ninu àkùrọ̀. Ẹniti o sanra ni, o soro lati gbé. Ti ejo ba si bu eniyan jẹ, aarẹ yoo ba oluwarẹ laarin iṣẹju melo kan, tobẹẹ ti oluwarẹ yoo fẹrẹ kú. Leo wà nibẹ. Nkankan si wá si ọkan mi, wipe, “Iwọ ni Ọlọrun sibẹ!” Nigbati o di ọwọ́ mọ́ ẹsẹ̀ rẹ̀, ti o si di i mu, pẹlu oju iho nla meji, nibiti ejo naa ti bu u jẹ, mo gbe ọwọ le ibẹ, mo si wipe, “Oluwa, a kọ ọ ninu Ọrọ Rẹ, wipe, ‘Wọn yoo tẹ ejo ati akeekee mọlẹ, ohunkohun ki yoo pa wọn lara, bi o ti wu ki o ri.” Ni iṣẹju aaya yẹn, gbogbo irora fi ẹsẹ rẹ̀ silẹ. O wọ bata rẹ, a si pa ẹja ni gbogbo ọjọ́ naa.

41 A lọ si ile ni alẹ ọjọ́ naa, a si sọ fun wọn nipa rẹ, wọn ni, “Ó sàn ki o lọ sọdọ dokita.”

42 O ni, “Ti Ọlọrun ba daabo bo mi titi di isisiyi, Oun yoo tọju mi titi de opin.” A pẹja fun ọjọ́ mẹta, ko tilẹ si ipalara kankan rara.

43 Ọlọrun jẹ Ọlọrun sibẹ. O n mu gbogbo ileri ṣẹ. Ninu gbogbo iṣẹ-iriju iwaasu mi, igba àkókó niyẹn ti n o ri ki Ọlọrun wa soju agbo fun ẹniti ejo bu jẹ, nitori igba akọkọ niyẹn ti n o ni anfaani lati gbadura fun ẹniti ejo bu jẹ. O fẹ ki a mọ wipe Oun n mu gbogbo ileri Oun ṣẹ, Ọrọ Rẹ̀ dara, otitọ si ni wọn. Amin.

44 Ẹ ranti awọn isin aṣalẹ oni ati Ọjọ́ru ti o n bọ. Ẹ gbadura fun ẹnikan ti o nilo adura gidigidi bayi, iyẹn ni emi. Ẹ si ranti lati lọ sibi ipade Arakunrin Roberts nigbati o ba de si aarin ilu, ki ẹ si ki i ni orukọ ile-ijọsin yii.

45 Ki a to ka Iwe Mimọ, mo—mo fẹ ki a dide duro lori ẹsẹ̀ wa fun iṣẹju kan. Laisi duuru, ẹ jẹ ki a kọ orin èbè kan tabi meji ninu iwe-orin atijọ ti ijọ yii, *Igbagbọ Mi N Wo Ọ*. O dara, ki gbogbo eniyan darapọ pelu mi bayi, ẹ je ki a kọ ọ. Maṣe ronu nipa bi iwọ ṣe n kọrin, iwọ ṣaa kọ ọ fun ogo Ọlọrun. Ṣe ẹ o dari wa ninu orin naa, Arakunrin Neville?

Igbagbọ mi n wo Ọ,
Ọdọ-aguntan Kalfari,
Olugbala;
Gbọ gba mo ba n pe Ọ,
Mu ẹ̀ṣẹ̀ mi kuro,
A lati oni lọ,
Ki n jẹ Tirẹ!

Gba mo n la okunkun aye lọ,
Ti banujẹ yi mi ka,

Ṣ'amọna mi;
Sọ oru mi d'ọsan,
Mu 'banujẹ kuro,
Ma jẹ ki n ṣako lọ
Ni ọ̀dọ̀ Rẹ.

46 Pẹlu bi a ṣe tẹriba, mo fẹ lati ka lati inu akọsilẹ mimọ ti Bibeli, Matteu Mimọ, ori keje, ẹsẹ ikẹtala ati ikẹrinla. Ki Oluwa fi ibukun Rẹ si i bi a o ṣe ka a.

Ẹ ba ẹnu-ọna híhá wọlé: nitori gbòòrò ni ẹnu-ọna naa, onibu si ni oju ọna naa, ti o lọ sibi iparun*, ọpọlọpọ si ni awọn ẹniti n ba ibẹ wọle.*

Nitoripe hiha ni ẹnu-ọna naa, ati tooro ni oju ọna naa, ti o lọ si ibi ìyè, diẹ si ni awọn ti o n rin-in.

47 Ẹ jẹ ki a gbadura. Ọlọrun o, Ẹniti o tun mu Jesu Oluwa kuro ninu òkú, ati lati inu iboji, ti O si ti fi fun wa ni owuro yii gẹgẹbi Ẹbọ aaye, pẹlu irẹlẹ ni a fi aye wa jin fun Ọ ni ọ̀tun, pẹlu èrò wipe Iwọ yoo fi wa sọkan gidigidi. Nigbati a jẹ ẹlẹ́ṣẹ̀, ti a ku ninu ẹ̀ṣẹ̀ ati irekọja, O rán Ọmọ bibi Rẹ kanṣoṣo, ti a dá ni ìrí ara ẹ̀ṣẹ̀, ki Ó lee di ètùtù fun ẹ̀ṣẹ̀ wa, ki Alaiṣẹ, bi o ṣe n jiya fun ẹniti o jẹbi, ki Ó lee bá wa làjà pada ni idapọ pẹlu Rẹ.

48 Ọlọrun o, bi ẹ̀ṣẹ̀ ba wà laarin wa ni owuro yii, ohun kan ti o lee di Ẹmi Mimọ lọwọ lati mu Iṣẹ-iranṣẹ Ọlọrun wa si ọkan ẹnikọọkan wa, a gbadura pẹlu irẹlẹ, Oluwa, wipe ki O dari gbogbo irekọja wa jì wá. Fi Ẹjẹ Jesu Oluwa wẹ̀ wá mọ́. Ẹniti…Awa mọ, ninu ara wa, wipe awa ko jẹ nkankan, a si jẹwọ wipe a ko jẹ nkankan. Ṣugbọn mimọ ni Iwọ, olootọ ni Iwọ, olododo ni Iwọ, Iwọ ni orisun aanu. A si fi irẹlẹ fa wa sibẹ loni, gẹgẹbi ọkan ti o ti ronupiwada. Gẹgẹbi ẹri kan ti jade lọ, lati Jamaica ati lati Puerto Rico, ati ibiti Iwọ ti ṣe awọn iṣẹ nla naa, Ọlọrun o, ó jẹ ami bibọ Olododo naa.

49 Iwọ gba Arakunrin Evans kuro lọwọ oró ejo nni, nitoripe oun jẹ onigbagbọ, otitọ si ni awọn Ọrọ Rẹ nigbagbogbo. Nisisiyi, Oluwa, gba wa lọwọ oro iku ni owuro yii, nibiti ọ̀tá ti bù wá jẹ, ti ó sì dá wa lóró. Jẹ ki òjíá iwosan Rẹ, ni owuro yii, Oluwa, wọ inu ẹmi wa, ki ó si wẹ wa mọ kuro ninu gbogbo aisododo. Wo aisan ti ara san, eyiti o ti wó lulẹ nipa agbara ọ̀tá. Gbogbo awọn ti o wà Niwaju Oluwa, jẹ ki wọn ri iwosan gba.

50 Ba wa sọrọ nisisiyi nipasẹ Ọrọ Rẹ ti a kọ silẹ, Oluwa. A ko mọ ohun ti o yẹ ki a sọ, ṣugbọn Iwọ yoo pese rẹ̀. Kilọ fun wa, Oluwa, ki O si pese wa silẹ fun Bibọ Rẹ. Eyi ni a beere ni Orukọ Jesu ati nitori Tirẹ̀. Amin.

51 Mo maa n pẹ diẹ, nitoripe mo ti duro nisisiyi. Mo si lero wipe ileẹkọ Ọjọ́ Isimi ti pari. Ṣugbọn nkankan wà nipa rẹ̀, nigbati mo ba dé si ilé, mo maa n lero wipe mo ni ọpọlọpọ àkókò. Njẹ ẹ mọ, a ti maa n kánjú jù. Nitorinaa, a o ṣaa gba Ọlọrun gbọ ni.

52 Oluwa wa n kilọ kikankikan fun awọn eniyan iran Tirẹ, awọn ti wọn jẹ ẹlẹ̀sìn gidigidi. O si wipe, “Hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, ti o lọ sibi Iye, awọn diẹ ni o si n rin-in.” Ni bayi, ki i ṣe nitoripe wọn kò jẹ́ ẹlẹ̀sìn gidigidi. Wọn jẹ ẹlẹ̀sìn gidigidi. Ati nitoripe wọn ti gbẹ̀kẹ̀le ijọ, ati awọn ẹ̀kọ́ adamọ kan, ati awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ kan, wọn si ti gbagbọ (de ipo kan) ninu Ọlọrun, wọn ro wipe ohun gbogbo ti dara tó. Ṣugbọn O n sọ fun wọn wipe awọn diẹ ni yoo wọle.

53 O n ya mi lẹnu ni owuro yii, boya n ko lee fi iran yẹn we iran yii. Ṣe ẹ mọ, o jẹ asiko ti igba awọn Juu ti fẹrẹ pari, O si n pada tọka si oniruuru awọn eniyan, ati oniruuru opin ti awọn oniruuru igba, O si n sọ fun wọn wipe awọn ohun ti a ti ṣe ni awọn iran ti o ti kọja lọ, ni a n ṣe niwaju wọn. Wọn si kuna lati da a mọ. Ẹ jẹ ki a wo diẹ ninu awọn nkan ti Ó n sọrọ nipa rẹ.

54 Fun apẹẹrẹ, wọn ko lee gbagbọ wipe Ọlọrun wa ninu Ọkunrin yẹn. Idiwọ ti o ga julọ ti wọn nilati bori rẹ̀ niyẹn, ni wipe bawo ni Oun ti o jẹ eniyan ṣe lee fi ara Rẹ̀ pe Ọlọrun. Ko ye wọn bi Ọlọrun ṣe lee maa gbe ninu ara eniyan. Ni gbogbo iran, ni gbogbo igba, ni Ọlọrun ti maa n gbe inu eniyan. Eniyan ni ohun èlò Ọlọrun. Ni gbogbo iran, Ọlọrun maa n bá awọn eniyan Rẹ̀ sọrọ nipasẹ èrè eniyan. Nigbagbogbo, O maa n yan ẹnikan tabi ohun kan ti O lee lò.

55 O tọka wọn pada si Abrahamu, eyiti o jẹ ikọṣẹ fun wọn. O sọ, O sọ fun wọn wipe, “Bi ẹyin ba pe ara yin ni ‘ọmọ Abrahamu,’ Abrahamu ‘baba’ yin, o ri ojọ́ Mi, o si yọ̀ lati ri i. Abrahamu, wolii naa.” Ko si iyemeji wipe Jesu n tọka wọn si i, wipe Oun ti fidi rẹ̀ mulẹ fun wọn wipe Oun ni Messiah, nitoripe àmì Messiah n tẹle E. Bi o ṣe maa n ri ni gbogbo iran niyẹn, iyẹn ami Messiah naa. Ṣugbọn wipe O n fi ara Rẹ̀ pe Ọlọrun, ani Messiah funra Rẹ̀, iyẹn mu wọn kọsẹ̀. Ko lee ye wọn.

56 Njẹ nigbati Abrahamu (ẹniti wọn pe ni baba wọn) bá Ọlọrun pàdé, O wà ninu ẹran ara pẹlu, nitoripe O jẹ ẹran maaluu, o si jẹ burẹdi ti a fi agbado ṣe (O tun mu wàrà) bẹẹni O jẹ òrí, niwaju Abrahamu, sibẹ, Oun ni Ọlọrun. Abrahamu da A mọ, gẹgẹbi Ọlọrun, o si pe E ni “Ẹlohimu,” eyiti i ṣe Jehofa Alagbara. Eniyan ti o wọ aṣọ, pẹlu eruku ni Ara Rẹ̀, ti o si joko sabẹ igi kan, labẹ ìji, O jẹ ẹran, O si mu wàrà. Awọn Juu ọlọ́kàn buburu, onimọ-tara-ẹni-nikan, ati olododo naa ko lee gbagbọ wipe Oun ni Ọmọ Ọlọrun, wọn si pe Abrahamu ni baba wọn. O si jẹ ki wọn mọ wipe nkan kannaa ni Oun

n ṣe, ninu ẹran ara Rẹ, eyiti Ọlọrun ṣe ninu ara miran nigbati O pade baba wọn, Abrahamu. Abrahamu si gba a gbọ. Ṣugbọn awọn ko lee gba a gbọ.

57 Njẹ ẹ mọ, Abrahamu joko sabẹ àgọ́ rẹ̀, nitoriti o ti yan nkankan, a si n fi anfaani lati yan siwaju olukuluku eniyan ti a bi sinu aye yii. Igi rere ati buburu wa niwaju olukuluku eniyan. Nigbati Lọọti, aburo rẹ, ti awọn darandaran wọn n jiyan lori ilẹ̀; Abrahamu, ti o jẹ olododo, sọ fun wọn wipe, “Ẹ maṣe jẹ ki ariyanjiyan wa laarin wa. Iwọ yan ọna ti o ba fẹ lọ.” Nkan yẹn maa n wá sinu aye gbogbo onigbagbọ. O wà niwaju rẹ ni owuro yii, o si wà niwaju mi pẹlu.

58 Lọọti kò ronu wipe oun yoo pada seyin, ṣugbọn o boju wo Sodomu, nibiti nkan ti rọrun. Ọpọ igba ni awa naa maa n wo ọna ti o rọrun. “Emi yoo darapọ mọ ijọ bayi-bayi, ṣe ẹ si mọ, ẹnikẹni ki yoo sọ ohunkohun lodi si i, nitori oun ni ijọ ti o tobi julọ laarin ilu.” Ọna irọrun! Ọpọ igba ni a maa n ṣe bẹẹ, bẹẹ si ni a kuna!

59 Ranti o, ti o ba tẹle Kristi, awọn eniyan yoo korira rẹ, nitori gbogbo awọn ti o ba n gbe igbe-aye iwa-bi-Ọlọrun ninu Kristi Jesu yoo farada inunibini. Ti o ba si tọ Kristi wá, iwọ ki yoo gba ọdọ ijọ kankan tabi ijọ elẹkọ-adamọ kankan wá, tabi ẹkọ adamọ kankan. Iwọ yoo ti ipasẹ Ẹ̀jẹ̀ wá, ọna abawọle kanṣoṣo ti o wà niyẹn. O ko si lee mu ẹlomiran dani pẹlu rẹ, iwọ nilati danikan wá, ki o si duro lori ìjẹ́wọ́ ati igbagbọ ti ara rẹ. O ko lee ti ipasẹ oluṣọ-aguntan wọle, tabi lori igbagbọ iya rẹ. O gbọdọ wá gẹgẹbi ẹnikanṣoṣo nigbati o bá tọ Ọlọrun wá! Ọpọ igba ni a si maa n yan awọn nkan omugọ wọnyẹn.

60 Iba ṣe wipe Lọọti, nigbati o ri i ti gbogbo nkan rọrun…? O ri ibiti owó pupọ ati okiki pupọ wa, nitoripe oun yoo jẹ́ alejo, ati ẹniti o jafafa, ọmọwe, pẹlu ọpọlọpọ ọpọlọ, oun lee ṣe awọn nkankan, ki o si di ẹsìn rẹ̀ mú sibẹ. O ronu wipe, “Mo ti ni igbagbọ ninu Ọlọrun, nitorinaa, emi yoo lọ si Sodomu, emi yoo si—emi yoo pa owó diẹ si i, emi yoo di ẹni nla, boya oniwaasu agbayanu kan.” Ṣe ẹ mọ, ẹ nilati yàn.

61 Ọmọ ijọ naa nilati yàn. “Emi yoo sọkalẹ lọ si ile ijọsin ti o wà nibẹyẹn, gbogbo ara ilu ni o mọ wipe oun ni o dara julọ! Kini, ọmọ ijọ yii ni alaga ilu yii.” Ó lee jẹ ọmọ ijọ kan ti o dara, ṣugbọn sibẹ, iwọ nilati ṣe odiwọn ijọ yẹn, ati awọn eniyan inu rẹ̀ nipa Iwe Mimọ. Igbamiran wọn maa n lọ sibẹ nitoripe ó jẹ ọna ti o gbajumọ—awọn ti o n lọ si ibikan bayi maa n mura daradara. Ibiti a ti n ṣe—aṣiṣe ti o buru julọ niyẹn. Ẹ kiyesi eleyi bayi.

62 Abrahamu ní tirẹ̀, ohun kanṣoṣo ti o lee ṣe ni wipe ki o gba ipò keji. Igbamiran, ipò keji dara ju ipo kinni lọ, ti a ba gba a bẹẹ. Ẹ kiyesi i, kò pẹ́, lẹyin ti Lọọti ri ilu nla yii, kò ri i wipe iyawo oun yoo

di ọ̀wọ̀n iyọ̀, kódà, ko ri ina ti yoo jó ilu naa run. Ṣugbọn Abrahamu yàn lati ba awọn eniyan Oluwa diẹ ti a n kẹgan rin. O duro si aṣálẹ̀.

63 Sibẹ, ti ó bá jẹ wipe Sarah ti sọ…Ẹ ranti bayi, Sarah ni obinrin ti o rẹwa julọ ni gbogbo ilẹ naa. Ko si obinrin ti o rẹwa to Sarah. Gbogbo awọn ti o ri i ni wọn nifẹ rẹ. O rọrun fun Sarah lati yan iru nkan bẹyẹn. Ṣugbọn o yàn lati duro ti Abrahamu.

64 Ah, ẹyin obinrin, ẹ maṣe jẹ ki eṣu fọ yin loju, lati jẹ olokiki, lati darapọ mọ *eyi* ati *iyẹn*. Ẹ duro ti Kristi! Nitori wakati naa ti sunmọ tosi, iparun nla n bẹ niwaju, ti o buru ju ti Sodomu ati Gomora lọ, fun orilẹ-ede yii. Kekere ni ti Sodomu ati Gomora yoo jẹ lẹgbẹ rẹ̀.

65 Nigbati Abrahamu gba ọna ti Ọlọrun yan fun-un, ti o si gba ibi ti ko lọra ninu ilẹ naa, ko ṣe rere rara. Ṣugbọn sibẹ, o mọ kini kan, o sin Ọlọrun, o si gba Ọlọrun gbọ.

66 Lọjọ kan, awọn ọkunrin mẹta kan wá, ara wọn kun fun eruku, aarẹ si mú wọn, aanu wọn ṣe Abrahamu, o si wipe, “Ẹ wa joko sabẹ igi oaku yii fun igba diẹ.” Bi o ṣe duro sibẹ ti o n ba wọn sọrọ, o mọ wipe wọn ki i ṣe eniyan lasan, nipa ọrọ ẹnu wọn. Wọn yatọ. Abrahamu si lọ pa maalu kan, o ni ki wọn kun-un, o ni ki Sarah lọ se burẹdi, ki o si mura lati fun wọn ni ounjẹ.

67 Ẹ ranti o, meji ninu wọn jẹ Angẹli, awọn Angẹli ninu ara eniyan, ọkan ninu wọn si jẹ Ọlọrun Funrarẹ. Ẹniti o jẹ Ọlọrun si kọ ẹyin Rẹ sí àgọ́.

68 Sarah duro sinu àgọ́. Mo maa n fẹ lati ri ki obinrin wà ni aaye rẹ bẹyẹn, ki i ṣe ki o jade lọ, ki o maa sọ ohun ti ọkọ rẹ gbọdọ ṣe, ni gbogbo igba ti ẹnikan ba ti wọle. Ṣugbọn o duro sinu agọ. Ko si iyemeji, boya o n fọ awọn abọ́, tabi o n ṣe nkankan.

69 Ẹniti o jẹ Ọlọrun yii, O ṣa n wo iha Sodomu ṣaa ni, O si sọ ohun ti Oun fẹ lọ ṣe fun wọn. Awọn Angẹli meji kọja lọ sibẹ lati waasu Ihinrere. Ṣugbọn Ẹnikan duro sẹyin, Ẹnikan yẹn ni Ọlọrun, O si wipe, “Emi ki yoo fi awọn aṣiri ti Mo mọ pamọ fun Abrahamu, nitori oun ni yoo jogun aye.”

70 Ah, a ni ẹtọ ni owuro yii, ẹyin ijọ, lati mọ awọn aṣiri Bibọ Oluwa. Nitori, “Ibukun ni fun awọn onilaja, nitori ọmọ Ọlọrun ni a o maa pe wọn. Ibukun ni fun awọn ti ebi n pa, ti oungbẹ si n gbẹ, wọn yoo yó. Ibukun ni fun awọn ọlọkan funfun, nitori wọn yoo ri Ọlọrun. Ibukun ni fun awọn oniwa tutu, nitori awọn ni yoo jogun aye.” Njẹ ti ijọ Ọlọrun alaaye yoo ba jogun aye, ko si aṣiri kankan ti a fi pamọ fun-un.

71 “Ohun gbogbo ti Baba ti sọ fun mi, ni Mo ti sọ fun yin,” ni Jesu wi. Wọn ko si lee gba A gbọ.

72 Nitorinaa, ni ọjọ́ Abrahamu, bi O ṣe n tọka wọn si i, O ni bi Abrahamu ṣe n ba Angẹli naa sọrọ lọwọ, O kọ ẹyin Rẹ si agọ, O si sọ fun Abrahamu wipe Oun yoo bẹ ẹ wo pẹlu ọmọ kan. Sarah wà ninu agọ, o si rẹrin. O si wipe, "Eeṣe ti Sarah fi rẹrin?" Kini O n fihan? "Eeṣe ti Sarah fi rẹrin?" Wakati diẹ ṣaaju iparun ni iyẹn ṣẹlẹ. Ṣaaju iparun, nigbati ina sọkalẹ lati ọrun wá, ti o si jo ilu naa run, a fi ami yẹn han.

73 Jesu sọ pe, "Ẹ kuna," si awọn ọjọ̀gbọ́n ninu ẹ̀sìn, si orilẹ-ede ẹlẹ̀sìn, nibiti o jẹ wipe ọ̀kẹ́ aimoye wọn ni o jẹ onigbagbọ. O ni, "Ẹ kuna, nitoriti ẹ kò mọ Iwe Mimọ tabi Agbara Ọlọrun." Sí iru iran bẹyẹn, awọn eniyan ti a ti kọ́ gidigidi, awọn ọmọwe, ti a tọ dagba ninu ijọ. Nigbati wọn ba bí ọmọ kan, o ti di ohun ini ijọ. O gbọdọ jẹ ọmọ Israẹli. Ọjọ́ mẹjọ lẹyin ti a bi ọ, ikọla yoo ṣẹlẹ, o ti di ọmọ Israẹli lati ilẹ wá niyẹn. Awọn alufaa si ti idile Lefi wa, awọn ti a fi ọgọọgọrun ọdun kọ́ ni Iwe Mimọ. Sibẹ Jesu wipe, "Ẹ kuna, nitoriti ẹ ko mọ Iwe Mimọ!" Wọn mọ wọn nipa ẹkọ iwe kika wọn, wọn mọ ọ nipa ẹkọ ijọ wọn, wọn mọ ọ nipa ẹkọ ẹ̀sìn wọn. Ṣugbọn Jesu wipe, "Ẹ kò mọ Ọ, iyẹn Iwe Mimọ, bẹẹni ẹ kò mọ Agbara Ọlọrun. Iba ṣe wipe ẹ mọ Abrahamu ni, ẹ ba mọ Mi. Iba ṣe wipe ẹyin jẹ ọmọ Abrahamu ni, ẹ kò ba mọ̀ Mi, nitoripe Abrahamu yọ̀ nigbati o ri ọjọ́ Mi, nitoripe o ri ọjọ́ naa ṣaaju. Nigbati mo duro niwaju rẹ̀ nigbayẹn, ninu ara eniyan, ti Mo si ṣe nkan yii, o mọ wipe Emi ni, o si pe Mi ni 'Ẹlohimu.' Ṣugbọn nkan kannaa ni Mo ṣe niwaju yin yii, ẹyin si pe Mi ni 'Beelsebuubu.'"

Wọn sọ pe, "Ah, Abrahamu ni baba wa."

"Ṣe ẹ pe Abrahamu ni 'baba' yin?"

74 Wọn ni, "Kini, awa, ọmọ ijọ ni awa. Orilẹ-ede ẹlẹ̀sìn ni wá. Eniyan nla ni wá. Eniyan Ọlọrun ni wá!"

Jesu wipe, "Ti ẹṣu ni ẹyin i ṣe, oun ni baba yin."

75 Ṣe mo lee fi iran yẹn wé eyi, lọjọ́ oni, nigbati o jẹ wipe ọ̀kẹ́ aimoye eniyan ni o n jẹwọ wipe Kristẹni ni awọn, ti wọn kò sì mọ̀ nipa Ọlọrun gẹgẹbi awọn Alawọ Dudu ko ti mọ nipa alẹ́ Egipti. Awọn ọkunrin ati obinrin wà loni, ọ̀kẹ́ aimoye awọn Kristẹni alafẹnujẹ, ti wọn n sọ wipe awọn ní Kristi, ti wọn kò si mo ipilẹ àkọ́kọ́ Agbara ajinde Rẹ̀, ti wọn kò si tọ́ oore Rẹ̀ wò rí. Wọn kò fi igba kankan mọ Agbara Rẹ ninu ara wọn. Oju wọn fọ si Otitọ.

76 O ni,"Ẹ fọju, adari awọn afọju si ni yin. Ṣe…ti…ti afọju ba n dari afọju, gbogbo wọn ki yoo ha ṣubu sinu kòtò bi?"

77 Lẹyinnaa, wọn ronu wipe, "Kristẹni ni wa. Onigbagbọ ni wá. Ọmọ ijọ ti o tobi julọ ni wá. Awọn alufaa wa ni awọn ọmọwe ti a kọ́ daradara julọ." Sibẹ, Jesu sọ fun wọn wipe wọn ko tilẹ mọ Iwe Mimọ.

78 Ṣe ẹ ri bi Ọlọrun ṣe fi pamọ kuro loju awọn ọlọgbọn ati amoye, ti O si fihan fun awọn ọmọ-ọwọ ti o ṣetan lati kẹkọ? Ah, Agbara Ọlọrun tobi, Ọlọrun kò sì ní opin! O dara si awọn ti o fẹ lati rin deedee niwaju Rẹ! Ki yoo fa ohun rere kankan seyin.

79 A si ti ri ọjọ́ naa, nigbati orilẹ-ede wa, ati aye wa, ti bajẹ pẹlu nkan kannaa!

80 Jesu n fẹ lati tọ́ wọn sọna. Wọn ni, “Ah, Abrahamu ni baba wa. Awa yoo si wà ninu Ogo, Iwọ ma ṣe iyọnu nipa iyẹn, nitoripe awa gbagbọ ninu Ọlọrun. Ọjọ́gbon ni wá, a si gbagbọ ninu Ọlọrun, a si n kọ awọn eniyan wa. Tani Iwọ lati wa sibi yii pẹlu—àmì àjèjì kan, ki O si gbiyanju lati pe e ni Ọlọrun? Beelsebuubu lasan ni Ọ.” Bi o ṣe ri niyẹn, wọn ní ẹkọ-adamọ wọn ati ijọ elẹkọ-adamọ wọn.

Jesu sọ fun wọn wipe, “Eṣu ni yin.” Ẹ ronu nipa rẹ!

81 Mo fẹ fi iran yẹn we eyi, loni ti a ni ẹgbẹlẹgbẹ ti wọn n darapọ mọ awọn ijọ, a ni ẹgbẹẹgbẹrun. Ọlọrun si sọkalẹ wá lati tun maa gbe ninu ijọ Rẹ̀, ati lati ṣe nkan kannaa ti Ó ṣe ni igba yẹn, lati fi ara Rẹ̀ han gẹgẹbi ọkannaa lana, loni, ati titi lae. Awọn eniyan si n kọ ẹyin wọn si i, ni gbogbo igba, awọn kan nitoripe wọn fẹ́ jẹ́ olokiki, awọn kan nitoripe wọn kò fẹ lati yan. Ṣugbọn o ti di tipatipa fun awọn eniyan! O nilati yan. O ko lee duro si agbedemeji. O nilati sọ pe “bẹẹni” tabi “bẹẹkọ.” O ko lee jade ni ẹnu ọna yẹn, ki o si ri bakannaa bi o ṣe wọle wá. O ko lee ṣe e. O ni ohun kan lati yan. Yan fun Kristi ni owurọ yii.

82 Wọn ro wipe gbogbo ẹniti o wà ninu ijọ ni a o gbala. Jesu wipe, “Hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, awọn diẹ ni o si n rin-in.”

83 Ẹ jẹ ki n kilọ fun yin ni owurọ yii, ẹyin ijọ, ẹ kiyesara. O n gba àkókò loni, ninu iran ododo-ara-ẹni, ati mo-tó-tán agabagebe ti a n gbe inu rẹ yii. Wakati naa niyi, ti awọn ọkunrin ati obinrin n duro ninu ijọ, ti wọn si n joko sinu aga, ti wọn n kọ orin Ọlọrun, ti wọn yoo si tun jade kuro ninu ijọ yẹn, ti wọn yoo si lọ mu siga, ti wọn yoo mu ọti, ti wọn yoo lọ si ile ijó, ti—ti wọn yoo si maa gbe igbe-aye wọn fun aye, ti wọn yoo maa ṣe èfẹ́ tí kò tọ́, ti wọn si n pe ara wọn ni “Kristẹni.” Nigbati awọn ọkunrin ati obinrin lee kuro nibi pẹpẹ tabi kuro ninu ijọ, ati nibi Agbara ajinde, nibiti àmì Messiah ti n farahan laarin wọn, ti wọn kò si ni di ẹda titun ninu Kristi, nkankan ti kuna. Nigbati awọn iwe-iroyin n pariwo rẹ̀ tantan; lati erekusu de erekusu, si iwaju ati si ẹyin, lati ibi yinyin ni Ariwa titi de ẹgàn ni Gusu, Ọlọrun n fi ranṣẹ, awọn eniyan si n kọ ẹyin wọn si i ni gbogbo igba. Kini a wa lee sọ nigbanaa, kini a lee ṣe? A o pada sinu Iwe Mimọ nibiti O ti sọ pe, “Hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, awọn diẹ ni o si n rin-in.”

84 O ni, “Bi o ti ri ni ọjọ́ Noah, bẹ̀ẹ̀ ni yoo ri nigbati Ọmọ eniyan yoo de.” Ẹ feti silẹ, ni ọjọ́ Noah, eniyan pọ ni aye gẹgẹbi o ṣe ri loni. Imọ-ijinlẹ wọn ga ju tiwa lọ. Wọn ṣe èrè ti o ní ori eniyan pẹlu ara kiniun, wọn si kọ́ ile ti o fẹ̀ ni isalẹ, ṣugbọn ti o ni òrùlé ṣonṣo, wọn si ṣe awọn nkan ti awa ko lee ṣe loni. [Ibi yii ṣofo lori fanran—Onkọwe.] Ẹni nla ati ọjọ́gbon ni wọn. Ẹ si ranti, imọ-ijinlẹ sọ loni wipe, “Ọganjọ-oru ku iṣẹju kan.” O ku iṣẹju kan ki agogo lu. Ọjọ́ ti lọ ju bi a ti ro lọ. Mo lero wipe—mo gbagbọ wipe Ẹmi Mimọ yoo fi eyi si ọkan gbogbo onigbagbọ, “bi o ṣe ri ni ọjọ́ Noah”!

85 Ẹni melo ni a gbala ni ọjọ́ Noah, ninu gbogbo iran yẹn? Ẹni mẹjọ, ẹni mẹjọ ninu ọpọlọpọ ẹgbẹẹgbẹ̀rún. O ni, “Bẹẹ ni yoo ri nigbati Ọmọ eniyan yoo de.”

86 “Ati bi o ṣe ri ni ọjọ́ Sodomu, bẹẹ ni yoo ri nigbati Ọmọ eniyan yoo de.” Ninu ẹgbẹẹgbẹ̀rún, eniyan mẹta pere ni a gbala.

87 Iwọ yoo wa sọ fun mi pe, “Iwọ oniwaasu, awọn ẹgbẹẹgbẹ̀rún ti yoo ba A wá nkọ?” Ni bayi, arakunrin, ninu ọpọlọpọ iran ni awọn wọnyẹn ti jade wá.”

88 Yoo ya mi lẹnu bi ẹni mejila baa lee jade ninu iran yii. “Hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, ṣugbọn awọn diẹ ni o n rin-in.”

89 Mo mọ ohun ti awọn ijọ n sọ, “Ti o ba fi orukọ rẹ sinu iwe, ti o si di ọmọ ijọ *yii*, ó ti dara tó.” Ko si Iwe Mimọ ti ó sọ bẹẹ. Ti ó ba jẹ wipe gbogbo awọn ti orukọ wọn wà ninu iwe ni, ati ninu—ninu ijọ, ẹgbẹlẹgbẹ lọna ẹgbẹlẹgbẹ lọna ẹgbẹlẹgbẹ ni yoo wà, gbogbo wọn ni yoo wọle. A jẹ wipe oniruuru ẹmi ni yoo wà nibẹ, iru ipo wo ni Ọrun yoo wà? Ẹ ronu nipa rẹ̀ bayi.

90 Ẹnikan lee sọ fun mi, wipe, “Duro na, Arakunrin Branham. Ẹni *bayi-bayi*, mo gbọ ti wọn n fedefọ, mo mọ wipe wọn yoo de ibẹ.”

91 Iyẹn ko sọ wipe wọn yoo de ibẹ rara. Pọọlu sọ ninu iwe Kọrinti Kinni, ori ikẹtala, wipe, “Bi mo tilẹ n fọ oniruuru ede ati ti Angẹli, ti emi ko si ni ifẹ, emi ko jẹ nkankan.”

92 “Ah, mo lọ si ipade ẹni *Bayi-bayi*. Ah, o ṣe nkan nla, iṣẹ ti o lagbara. Mo ri i ti o la oju afọju.”

93 Sibẹ o lee sọnu. “Ọpọ ni yoo tọ Mi wa lọjọ́ naa, wipe, ‘Oluwa, emi ko ha ti waasu ni Orukọ Rẹ bi, mo si ti sọtẹlẹ? Ni Orukọ Rẹ, emi ko ha ti lé ẹmi eṣu jade bi? Ni Orukọ Rẹ, emi ko ha ti ṣe ọpọ iṣẹ agbara bi?’ Oun yoo si wipe, ‘Ẹ kuro lọdọ Mi, ẹyin oniṣẹ ẹ̀ṣẹ̀, Emi ko tilẹ mọ yin ri.’” “Hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, awọn diẹ ni yoo si rin-in.”

94 Ẹ jẹ ki n fun yin ni iṣiro diẹ ti yoo mì yin titi. Ni ibamu pẹlu imọ-ijinlẹ iṣegun, ni ilu Chicago, gẹgẹbi akọsilẹ awọn dokita, wipe

ẹgbẹrun lọna ọgbọn ni oyun ṣiṣẹ ti o n ṣẹlẹ ni ilu Chicago nikan, ni ọgbọn ọjọ́, eyiti awọn dokita kọ silẹ. Melo ni awọn oogun ké-kè-ké ti wọn n lo yii, lati fi ṣẹ́ oyún?

95 Akọsilẹ fihan, ni Orilẹ-ede Amẹrika, wipe awọn ọmọ àlè ti wọn n bi pọ ju awọn ọmọ ọkọ lọ. Njẹ ẹ mọ wipe Bibeli sọ, ni Deuteronomi 14:2, wipe, “ọmọ ale, yoo to irinwo ọdun ki o to dopin”? Awọn ọmọ, ọmọ, ọmọ, ọmọ, ọmọ wọn ko lee duro laarin ijọ Oluwa, fun irinwo ọdun, iran mẹwa niyẹn. Ogoji ọdun ni iran kan. Awọn baba, baba, baba, baba, baba, baba, baba nla wọn jẹ ọmọ àlè, a ko ka a mọ ọmọ! Kini yẹn? Ẹ fi ibiti o ti yipada han mi.

96 Ibo ni a de duro? Ni bayi, awọn ọmọ àlè, nitori panṣaga, ati awọn obinrin ẹlẹ́ṣẹ̀, ti wọn n wọ aṣọ loju popo bii ọkunrin, eyiti i ṣe irira niwaju Ọlọrun, awọn ọmusiga, awọn ọmuti, awọn ti wọn n pe ara wọn ni Kristẹni. Ki Ọlọrun maṣe fi aaye gba iru awọn aṣẹwo bẹẹ! Bẹẹ ni. Wọn si n pe ara wọn ni Kristẹni? Abajọ ti Jesu fi sọ pe, “Hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, ṣugbọn awọn diẹ ni yoo rin-in.”

97 Wọn ki yoo rẹ ara wọn silẹ. Wọn ti gan. Ẹ wo o, nigbati a sọ fun Dafidi nipa ẹṣẹ ti ó dá, o ronupiwada kiakia, Ọlọrun si fẹran rẹ nitori iyẹn. Ti o ba sọ ẹṣẹ wọn fun wọn, wọn yoo sọ pe, “Emi ki yoo lọ si ile-ijọsin yẹn mọ.” Nitori kini? Wọn ní ọpọlọpọ ibi ti wọn lee lọ, wọn lee lọ si awọn ihò ọmọ-àlè yẹn, ti yoo fi aaye gba iru nkan bẹẹ. Ṣugbọn àkókò ti tó, ti o yẹ ki awọn oniwaasu gbe gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ, ki wọn si waasu Ọrọ naa lai gba ibọde, ani Ihinrere naa. Awọn eniyan gbọdọ rẹ ara wọn silẹ.

98 Ko si otitọ ọkan laarin awọn Kristẹni mọ. Wọn fẹ sọ wipe, “Ọmọ Ijọ Eleto ni mi, ọmọ Ijọ Onitẹbọmi ni mi, ọmọ Ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ni mi,” iyẹn ko jamọ *nkankan* lọdọ Ọlọrun. [Arakunrin Branham tàka—Onkọwe.]

99 “Mo fedefọ, mo ṣe iṣẹ iyanu.” Iyẹn ni a n tẹnumọ, bẹẹ ni iyẹn jẹ ọkan ninu ohun ti o n fọni loju julọ ti wọn lee ṣe. Dajudaju. ojo n rọ sori olododo ati alaiṣododo. Ojo n rọ sori ewebẹ ati koriko, Roy. Ojo kannaa, Ẹmi Mimọ kannaa ni o n bà lé awọn eniyan. Sibẹ iyẹn ko tumọ si…Iwa ẹda wọn nilati yatọ, lati inu jade si ita. Ki i ṣe ifarahan tabi aṣehan ti ita, ṣugbọn Ẹmi Ọlọrun ní inu, eyiti yoo sọ ẹni yẹn di ẹda titun, eyiti yoo rẹ ọkan ọkunrin tabi obinrin silẹ niwaju Ọlọrun.

100 O lee sọ pe, “Iwọ oniwaasu, ṣe o fẹ sọ fun mi wipe iwọ ṣiyemeji wipe ẹni mejila lee lọ ninu ọkẹ́ aimoye ati biliọnu mẹrin awọn eniyan ti o wà ninu aye yii?” Mo tilẹ ṣiyemeji boya ẹni mejila lee lọ ninu Igbasoke. Ẹ ronu nipa rẹ! Mo n sọ ohun ti Jesu sọ ninu Ihinrere fun yin. Ẹ ronu nipa rẹ!

101 Nibo ni a de duro? Nitoripe iwa aimọ ti gbilẹ laarin awọn eniyan, wọn bẹ̀rẹ̀ si bi awọn ọmọ ale, eyiti o yọ wọn kuro. A lee duro sibi yii fun ọpọlọpọ wakati, ki a maa fi awọn nkan yẹn si aaye wọn, ẹ o si ri i wipe a n gbe laarin iran awọn eniyan ti o ti dibajẹ, awọn ẹni ègbé, iran awọn ti o ti rà kan egungun. Abajọ ti wọn kò fi ri àmì kankan, abajọ ti wọn kò fẹ gbọ Ihinrere, ọkan wọn ti le, sibẹ, wọn jẹ ẹlẹ̀sìn gidigidi.

102 Jesu ko ha ti sọ bẹẹ bi, wipe, “Ẹmi n tẹnumọ ọ gidigidi, wipe ni ikẹyin ọjọ́, awọn eniyan yoo jẹ olorikunkun, ọlọkan giga, olufẹ faaji ju olufẹ Ọlọrun lọ, òdàlẹ̀, alainitẹlọrun, ònrorò, alainifẹ ohun rere, wọn ni afarawe iwa-bi-Ọlọrun”? Ṣe ẹ ri i? Ah, o lee pariwo, dajudaju. O lee fedefọ, dajudaju. Igbagbọ yoo le èmí èṣù jade, dajudaju. Ṣugbọn ohun ti a n sọ kọ́ niyẹn.

103 O wá lee sọ fun mi, wipe, “Arakunrin Branham, kini àmì Kristẹni? Tani a o gbala? Ṣe a o gba iwọ là, Arakunrin Branham?” Mo n gba Ọlọrun gbọ fun iyẹn. Emi kò mọ̀. Mo n gbagbọ wipe mo wa nibẹ. Mo n yẹ igbe-aye mi wò, lojoojumọ, pẹlu Ọrọ naa. Ti ko bá bá Ọrọ yii mu, a jẹ wipe nkankan ti kuna, mo nilati pada lọ ṣe atunṣe.

104 O lee sọ pe, “O dara, Arakunrin Branham, nigbati awọn eniyan ba fedefọ, ṣe iyẹn kò sọ wipe a ti gba wọn là niyẹn?” Rara, sà! Rara, dajudaju! Mo ti gbọ ti awọn àjẹ ati oṣó n fedefọ, ti wọn n sọ oniruuru. Mo ti ri awọn eniyan ti wọn n fedefọ, ti wọn si tun n yan iyawo oniyawo ni àlè. Mo ti ri awọn eniyan ti wọn n fedefọ, ti wọn n fo soke sodo, ti wọn si n pariwo bii igbati ile ba n jóná, ti wọn yoo si jade lọ lu jibiti, ti wọn yoo jale, ti wọn yoo parọ, ati ohun gbogbo. Bawo ni ẹ ṣe lee reti nkan bẹyẹn? Rara, sà.

105 Wọn jẹ ọmọ ijọ, wọn jẹ diakoni ninu ijọ, wọn jẹ ẹni rere gidigidi. Ṣe ẹ ro wipe wọn yoo ra epo si ọkọ ayọkẹlẹ wọn ni Ọjọ́ Isinmi? Rara. Ṣugbọn ni Ọjọ́ Aje, wọn yoo ṣe nkan idọti ati nkan ibajẹ. Inu ọkàn ni Ọlọrun n gbe, ki i ṣe ita, ohun ti o ti inu ọkàn wá ni.

106 “Hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, diẹ si ni awọn ti o n rin-in.” Bi o ṣe ri ni ọjọ́ Noah, ẹni mẹjọ ninu ẹgbẹẹgbẹ; bi o ṣe ri ni ọjọ́ Sodomu, ẹni mẹta ninu ẹgbẹẹgbẹ; bẹẹ ni yoo ri nigbati Ọmọ eniyan yoo de.

107 Ẹ si ri iwa ibajẹ ti a wà ninu rẹ. Ẹ ri i bi gbogbo èrò eniyan ṣe rí, eniyan yoo jade lọ, eṣu yoo si jẹ ki awọn ọ̀jọ̀gbọ́n oniwaasu duro sori pẹpẹ iwaasu, yoo si jẹ ki awọn eniyan gba a bẹẹ.

108 Ni ijelo, ẹnikan sọ pe, “Emi ko lee fi aaye gba ọ lori pẹpẹ iwaasu mi, iwọ yoo mu ki awọn obinrin mi ya wèrè.” Rara, wọn ti da bẹẹ na. Yoo mu ki ori wọn pé ni, yoo sọ fun wọn wipe ki wọn dẹkun ati

maa wọ awọn aṣọ wọnyi, ati awọn nkan miran. Bẹẹni, ẹnikan nilati ṣe iṣẹ yẹn.

109 Mo sọ fun iyawo mi, wipe, “Ṣe emi pẹlu ti ya wèrè ni? Ṣe ori mi ti daru ni? Tabi kini o tilẹ n ṣe mi?” Nkankan ninu mi ko lee dakẹ jẹẹ. Mo gbọdọ sọ Ọ, emi ko bikita ohun ti ẹnikẹni sọ.

110 Wọn ni, “Iwọ yoo ba iṣẹ-iriju iwaasu rẹ jẹ.” Ko buru, iṣẹ-iriju iwaasu yoowu ti Ihinrere yoo ba bajẹ, o yẹ ki o bajẹ.

Ki Ọlọrun fun wa ni igboya lati duro lori ohun ti o jẹ Otitọ, ki a si sọ Otitọ nipa rẹ! Ẹṣẹ ni, itiju ni!

111 “Hiha ni ẹnu-ọna naa,” ni Jesu wi, “tooro si ni oju ọna naa.” Ẹyin ti ẹ rò wipe ẹgbẹlẹgbẹ eniyan ni, ati wipe gbogbo ẹyin Ijọ Eleto, Ijọ Onitẹbọmi, Ijọ Alagba, ati ẹyin Ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ni yoo wọle, a o tan yin jẹ lọjọ yẹn. Jesu wipe, “Ọpọ ni yoo wa joko ninu Ijọba naa, wipe, ‘Mo ni ẹtọ lati wa nibi yii.’” O ni, “Ṣugbọn awọn ọmọ Ijọba naa yoo lé wọn jade. Nibẹ ni ẹkún, òṣé oun ipayinkeke yoo gbe wà.” O sàn ki a ṣe ayẹwo ni owuro yii, ẹyin Kristẹni. Ọkẹ aimoye awọn ẹgbẹlẹgbẹ ti wọn pe ara wọn ni Kristẹni ni yoo wa nibẹ, awọn ti wọn jẹ olootọ ninu igbe-aye wọn, ti wọn yoo si padanu ẹnu-ọna naa. Jesu sọ bẹẹ.

“Ẹni melo ni yoo wọle?”

112 Emi ko mọ iye awọn ti yoo wọle. Ohun ti mo mọ ni pe, “Ọlọrun, jẹ ki n jẹ ọkan ninu wọn!” Bẹẹ ni. Oun ni Onidajọ. “Jẹ ki n jẹ ọkan.”

113 O lee sọ pe, “Arakunrin Branham, bawo ni a ṣe lee dá Kristẹni mọ?”

114 Emi ko mọ. Ṣugbọn jẹ ki n sọ ohun ti Iwe Mimọ sọ fun ọ. Dajudaju, ẹ gba Iyẹn gbọ. Nigbati a ran Ẹmi Mimọ wá sinu aye, Ọlọrun sọrọ nipasẹ Ẹmi Mimọ. O ran Angẹli kan jade—jade lakọkọ. O si wipe, “La ìlú naa já, ati aarin awọn eniyan naa, ki o si ṣe àmì siwaju wọn, awọn ti wọn n mi ìmí ẹdùn ti wọn si n sọkun nitori awọn ìríra, ti wọn si n ṣe atunṣe awọn nkan wọnni.”

115 Kini irira? Obinrin ti o wọ aṣọ ọkunrin. O n run Ọlọrun ninu. Njẹ ẹ tilẹ de ibiti ohun irira wà rí? Yoo mu inu run ọ! O ko lee fara da a. Obinrin ti o wọ aṣọ ọkunrin, bi o ṣe ri lara Ọlọrun niyẹn; o lee kọrin ninu ẹgbẹ akọrin, o lee gbadura lojoojumọ, ki o si maa pariwo lojoojumọ, tabi ki o maa gbe igbe-aye fun Ọlọrun lojoojumọ, a ti da ọ lẹbi Niwaju Ọlọrun. Ohun ti Iwe Mimọ sọ gan-an niyẹn. “Ohun irira!” Awọn ti o si gba iru nkan bẹẹ laaye, yoo ni ipin pẹlu iru nkan bẹẹ.

116 Ki Ọlọrun fun wa ni oore-ọfẹ lati tako iru nkan bẹẹ. Ti o ba nilati dá nikan duro, duro sibẹ, ki o si di Ọrọ Ọlọrun mu ni ọwọ rẹ. Ki yoo kuna laelae.

117 A ti de ọjọ́ kan bayi, nibiti awọn eniyan ti n ṣe irira. Angẹli naa si tun ti n jade lọ lati ṣe èdídí bayi. Ẹ fi ẹnikan han mi ni Jeffersonville, ti ẹ ba fẹ mọ ẹniti yoo de ibẹ, ẹ fi ẹnikan han mi ni ilu wa, ẹniti o n kẹdun, ti o si n kerora ti o n daamu ti o si n kaarẹ ni gbogbo igba, ti o si n gbadura nitori irira ti wọn n ṣe laarin ilu. Ṣe ẹ lee na ọwọ yin soke, ki ẹ si tọka ẹnikan? Bi o ba ri bẹẹ, ẹ gba Iwe Mimọ, wipe, "Hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, ti o lọ si Iye, awọn diẹ ni o si n rin-in." Awọn yẹn nikan ni a o fi edidi di.

118 Ah, mo lee fi ọpọlọpọ ti o n lọ si ile-ijọsin han yin. Mo lee fi ọpọlọpọ ti o n kọrin ninu ẹgbẹ akorin han yin. Mo lee fi ọpọlọpọ ti o n kọni ni Ile-ẹkọ Ọjọ́ Isimi han yin. Mo lee fi ọpọlọpọ awọn ti o jẹ olori—ẹgbẹ nla-nla han yin. Mo lee fi ọpọlọpọ awọn ti o n pariwo han yin, ọpọlọpọ awọn ti o n fedefọ, ọpọlọpọ awọn ti wọn n ṣiṣẹ nibi Ihinrere.

119 Ṣugbọn ẹ fi ẹnikan han mi, ti o jẹ wipe ninu ọkan wọn, wọn n daamu nitori èṣẹ̀ ayé! Fi oniwaasu kan han mi, ti o lee dide duro loni, ki o si da awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ lẹbi. Fi oniwaasu kan han mi, ti o lee dide duro, ki o si sọ awọn nkan, ki o si da awọn ijọ ẹlẹkọ-adamọ lẹbi. O sàn ki ó má ṣe e, wọn yoo lee jade ni, ounjẹ òòjọ́ rẹ niyẹn.

120 Abajọ ti Billy Graham fi sọ fun Jack Moore, wipe, oun ko mọ bi awọn ipade mi ṣe n fẹsẹmulẹ, o ni, "Ki i ṣe ọmọ Ijọ Onitẹbọmi, bẹẹni ki i ṣe ọmọ Ijọ Eleto tabi ti Ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ." O ni, "Gbogbo wọn ni wọn si lodi si i." Dajudaju, emi ko sọ wipe…Idi ti mo fi sọ, emi ko lee sọ ọ ni gbangba. Ijọ mi ni mo n sọ ọ si. Mo n ni ìlàkàka kan, nitori wakati idanwo ti de ba mi.

121 Wọn ni, "Ti o bá wá, o dara, ṣugbọn iwọ maṣe sọ ohunkohun nipa Iyẹn." O kuku sàn ki ẹ dakẹ.

122 Emi yoo waasu ohun ti Ọlọrun ba sọ wipe ki n waasu! Bẹẹ ni. Ọkan ninu awọn mẹjọ naa yoo wà nibikan. Ọkan ninu wọn yoo wa nibikan. Ṣugbọn lọjọ yẹn, emi ko fẹ jẹbi wipe mo gbabọde nitori ẹkọ-adamọ kan tabi ẹkọ ijọ kan tabi ijọ elẹkọ-adamọ kan. Mo ti waasu otitọ!

123 Wọn ni, "Eeṣe ti iwọ, eeṣe ti iṣẹ-iriju iwaasu rẹ, Arakunrin Branham, eyiti o dabi ẹni wipe o lagbara, eeṣe ti ko fi gbilẹ bí ti awọn ọkunrin yooku ti n ṣe?"

124 Bi o ṣe ri gan-an niyen, bẹẹ ni. Ti mo ba lọ si awọn ilu kan, ṣe ẹ ro wipe Ijọ Assemblies yoo fọwọsowọpọ pẹlu mi? Emi ko gbagbọ bẹẹ, wọn ki yoo ṣe bẹẹ. A lee ri ẹyọkan lẹẹkọọkan. Ṣe ẹ ro wipe awọn Ijọ Eleto yoo ṣe e? Ẹ gbiyanju ki ẹ ṣe iwadi. Iwọ jẹ oludari awọn ipade mi fun òṣẹ̀ kan. Ti a ba lọ, a o lọ ni Orukọ Jesu ni. Bẹẹ ni.

125 Ṣugbọn ti wọn ba mu ọ lọ sibẹ, ti wọn mu ọ dé ibikan, ti iwọ kò si darapọ mọ wọn ni ọna yẹn. Nigbati o ba kuro nibẹ, wọn yoo sọ pe, “Ah, ni bayi, ori Arakunrin Branham ti yi diẹ, ṣe ẹ mọ. Ó…”

126 Ti ori mi ba ti yi, a jẹ wipe Bibeli ti yi kuro ninu Ẹkọ Rẹ niyẹn. Ohun ti Bibeli sọ niyẹn! Bẹẹni, sà. Ẹ kiyesi i!

127 Jesu wipe, “Eeṣe ti ẹ n pe Mi ni ‘Beelsebuubu’? Ẹ gba Solomọni gbọ, ani ami imọ-ẹmi-yatọ rẹ̀. Ẹ gba ọjọ́ rẹ gbọ. Ọbabinrin Gusu wá lati ipẹkun aye, lati ri ẹbun yẹn, o si gba a gbọ nigbati o ri i. Ẹyin si joko, ẹ n wo o lojoojumọ, ẹ kò si gba a gbọ.”

128 Awọn arakunrin Tirẹ gan-an kò gba A gbọ. Wọn ni, “Iwọ maa lọ sibi àsè,” Ó ní, “ṣugbọn Emi koi ti i lọ nisisiyi.” Ọna miran ni O gba lọ, nitoripe awọn arakunrin Rẹ ko gba A gbọ. Bẹẹ ni. “Híhá ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, awọn diẹ ni o si n rin-in.”

129 Nigbati o kan awọn ọmọ-ẹyin, ti o di ifagbarahan, nibo ni wọn wà? Obinrin kan ati ọkunrin kan ni wọn duro ti I nibi agbelebu, Johanu ati Maria. Awọn iyooku ti salọ.

130 Ifagbarahan naa niyi. Akoko naa niyi. Akoko yii ni Ọlọrun n ṣe awọn nkan. Akoko ti Messiah wà lori ilẹ aye niyi. Akoko yii ni Agbara Ọlọrun n ṣiṣẹ ninu awọn eniyan Rẹ̀. Wọn si n pe wọn ni “gbarayilẹ-mimọ, wèrè, asínwín,” ati iru awọn nkan bẹyẹn. Ṣugbọn wakati naa ti de!

131 Dajudaju, awọn ijakulẹ nla kan yoo wà nibi idajọ.

132 Ah, ọmuti, o mọ ibiti oun yoo wa nibi idajọ. Bẹẹ naa ni ẹniti o n le ọti kiri mọ ibiti oun yoo wà. Bẹẹ ni aṣẹwo mọ ibiti oun yoo duro si. Bẹẹ ni onitẹtẹ mọ ibiti oun yoo duro si. Bẹẹ ni ọmuti mọ ibiti oun yoo duro si. Oun ki yoo ni ijakulẹ.

133 Ṣugbọn ibiti ijakulẹ yoo ti ṣẹlẹ, ni awọn ti wọn ro wipe awọn tọna. Ibiti ijakulẹ yoo wà niyẹn. ”Nigbati wọn de ibẹ, wọn ní, ‘Dajudaju, a le ẹmi eṣu jade ni Orukọ Rẹ. Oniwaasu ni wá. Ọmọ ijọ bayi-bayi ni a jẹ. A ti ṣe iṣẹ iyanu nla. Ah, a waasu! Kini, emi ti jẹ—mo jẹ iranṣẹ ninu ijọ. Bisọọbu ni mi. *Bayi* ni mo jẹ.’ Ẹ kuro lọdọ Mi, ẹyin oniṣẹ ẹṣẹ, Emi ko tilẹ mọ yin ri.” Bi o ṣe ri niyẹn. Ijakulẹ naa niyẹn. O ni, “Awọn ọmọ-ọmọ wọn yoo wọle joko ninu Ijọba naa, wipe, ‘Awa ni ẹtọ́ lati wà nibi yii,’ a o si le wọn jade sinu okunkun biribiri, nibiti ẹkún, òṣé oun ipayinkeke yoo gbe wà.” Hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, ti o lọ sibi Iye, diẹ si ni awọn ti o n rin-in.”

134 Si ẹyin eniyan mi ọ̀wọ́n, ni owuro yii, ẹ feti si eleyi. Emi ko ro eyi tẹlẹ. Ojuṣe temi ni lati sọ Ọ. Ohun ti o jẹ ojuṣe temi niyẹn. Ti n kò bá waasu iwaasu miran mọ lọjọ aye mi, Otitọ niyẹn: awọn eniyan diẹ ni a o gbala. Ẹ ṣaa ranti iyẹn: eniyan diẹ ni. Iwọ jẹ ọkan ninu wọn.

135 “Awọn wo ni, Arakunrin Branham?” Emi ko mọ. Ko si ẹniti o mọ. A n ṣe iṣẹ́ igbala wa ni, pẹlu ẹ̀rù ati iwariri.

136 Ṣugbọn iwọ duro daradara pẹlu Ọlọrun. Ti ọkan rẹ ko bá bá Bibeli mu, a jẹ wipe nkankan kuna, nkankan kuna. Laibikita fun ohun ti ijọ rẹ sọ, o ko lee fi iyẹn wọle. O nilati wọle pẹlu ohun ti Ọlọrun sọ ni. Lati inu Iwe yii ni a o ti da ọ lẹ́jọ́, iyẹn Bibeli. Duro pẹlu Rẹ̀!

137 O lee sọ pe, “Ah, o dara, a ti baptiisi mi ni Orukọ Jesu Oluwa.” Iyẹn dara, Bibeli niyẹn. Ṣugbọn ti igbe-aye yẹn ko bá bá a mu, ko ṣe o ni rere kankan lati baptiisi.

138 O lee sọ pe, “O dara, mo ti gba Ẹmi Mimọ.” Iyẹn dara, ohun ti o yẹ ki o ti ṣe tẹlẹ niyẹn. Ṣugbọn ti igbe-aye yẹn ko ba si nibẹ!

139 Ẹ ranti, èpò n gba agbara kannaa ti o bà lé alikama lati mu ki ó dagba, oun naa ni o n mu ki èpò pariwo pẹlu. Èpò yoo dide duro, inu rẹ̀ yoo si dun gẹgẹbi ti alikama. Bẹẹ ni, ìyè kannaa ni wọn fi wa laaye. Ẹlẹ́ṣẹ̀ lee duro Niwaju Ọlọrun, ki o pariwo ìṣẹ́gun, ki ó si maa gbe gẹgẹbi Kristẹni. Ṣugbọn ti kò bá si nkankan ti o yatọ ninu ọkan rẹ! Oun naa lee ni Agbara kannaa lati lé ẹmi eṣu jade. Jesu sọ Bẹẹ. O lee waasu Ihinrere daradara gẹgẹbi eyiti gbogbo awọn oniwaasu lee ṣe. Bẹẹ gan-an ni, Jesu sọ Bẹẹ. Bibeli kọ́ ni Bẹẹ. Bẹẹni, sà. “Bi mo tilẹ n fọ oniruuru ede, ati ti awọn Angẹli, bi mo tilẹ fi ara mi fun ni lati sun bii ẹbọ, ti mo fi gbogbo ohun-ini mi bọ́ awọn talaka, ti mo—ti mo si ni igbagbọ lati ṣi awọn oke nidi, ti mo ṣe gbogbo nkan wọnyi, ti mo waasu ni Orukọ Rẹ̀, ti mo le ẹmi eṣu jade ni Orukọ Rẹ̀,” o ni, “emi ko jẹ nkankan.” Nitorinaa, ó lee ṣe e, sibẹ laijẹ “nkankan.” Ṣe o ye yin?

140 Ni bayi, ohun ti o yẹ ki a ṣe ni wipe, lati inu ọkan rẹ wá, jẹ Kristẹni, ki o si gba ẹnu-ọna hiha wọle nisisiyi. Nitori gbooro ni ọna naa ti o lọ si iparun, ọ̀kẹ́ aimoye ní iran alaigbagbọ yii ni yoo gba ibẹ wọle. Nitori hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, iwọ ati Kristi nikan ni.

141 “Hiha ni ọna naa ti o lọ sinu Iye, awọn diẹ ni o si n rin-in.” Ni bayi, Ọrọ Oluwa wa niyẹn. Kai! Kini O n ṣe? O duro sibẹ, O n mọ èrò ọkan wọn.

142 Wọn si wipe, “Beelsebuubu ni. O dara, bawo ni Ó ṣe lee jẹ Ọlọrun? Eniyan ni! Nibo ni ọgbọn yii ti wá?” wọn sọ bẹẹ ninu ilu Rẹ̀.

143 Nigbati eniyan ba wọ inu ilu yii, o dabi ẹni wipe…Emi ko sọ eleyi lati ri ẹyin eniyan yii fin o; Kristẹni ni ẹyin, ẹ fẹran mi. Nigbati eniyan ba wọ inu ilu yii, yoo dabi ẹni wipe agbara Satani lu oluwarẹ bolẹ. A ti da ibi yii lẹbi. A ti da ilu yii lẹbi.

144 Kini Billy Graham sọ nigbati o wọ inu Louisville? O sọ pe ibẹyẹn ni “ó kún fun agbara ẹmi eṣu julọ” ti oun ti i ri ri ni gbogbo ọjọ aye oun. O fi i sinu iwe iroyin, o ni, “Eniyan lee ni imọlara ipọnju eṣu.”

145 Otitọ ni, emi naa ni imọlara rẹ̀. Kini idi? Ilu temi ni eleyi. Nigbati Jesu pada sinu ilu ti Ara Rẹ̀, O ni ọpọ iṣẹ́ agbara ni Oun ko lee ṣe, nitori aigbagbọ wọn. O ni, “Wolii ko ṣe alaini ọla, ani oniwaasu, bikoṣe ninu ti ara rẹ̀—ninu ilu tirẹ̀, laarin awọn eniyan rẹ̀.” Ṣe o ye yin? Ko lee ṣe ki o ma ri bẹẹ, Iwe Mimọ ti sọ bẹẹ. Ṣe o ye yin?

146 Ni bayi, ti eniyan ba wọ inu ilu yii! Ma sọ fun mi wipe n kò ní mọ̀. Mo ti de ọdọ awọn eniyan ti yoo bọ̀ mí lọ́wọ́, ti wọn yoo si wipe, “Ah, Arakunrin Branham, mo fẹran rẹ.” Ẹ si mọ wipe irọ niyẹn! Ẹ mọ wipe irọ ni. Ti Ọlọrun ba lee sọ èrò ọkan awọn eniyan fun mi, kini ṣe ti Oun kò fi ni lee sọ iyẹn fun mi?

147 Dajudaju, laarin awọn eniyan yin ninu ilu yii ni! Ti wọn ba ri ọ, wọn yoo sọ pe, “O dara, njẹ o mọ, mo ri ibiti ẹni bayi-bayi…”

“Nibo? Nibo ni ibẹ?”

“Ni òkè ibẹyẹn…”

“Huh! A mọ ọkunrin yẹn!”

148 A ni imọlara rẹ̀. Jẹ ki n sọ fun ọ, jẹ ki ẹnikan ti kò fẹran rẹ wá si ile rẹ, ti ó bá joko sinu ile rẹ fun iṣẹ́ju melo kan, iwọ yoo ni imọlara kan. Ẹ ṣe ìlópo iyẹn ni ọna ẹgbẹrun mẹrinla, nigbanaa ẹ o mọ ohun ti mo n sọ. Ti o ba si de ibiti gbogbo eniyan ti fẹran rẹ, iwọ yoo ṣaa ni imọlara ifanimọra, kai, o lee duro sibẹ pẹ titi, ṣe ẹ ri i. Bẹẹ ni, ṣe ẹ mọ, èmí kan ni. Awọn eniyan kò si mọ ohun ti o jẹ́, o n yà wọn lẹnu bi awọn eniyan ṣe bajẹ to bẹẹ.

149 Kini o n mu ki awọn obinrin rere, kini o n mu ki awọn obinrin rere wọ aṣọkáṣọ, ki wọn si jade sita? Kini o faa, nisisiyi paapaa ti otutu mu, awọn ọmọbinrin ọdun mẹrindinlogun, pẹlu aṣọ lórùn, eyiti ko yẹ ki o wọ niwaju iya rẹ̀, yoo si wà loju popo? Ohun ti o fa a, ki i ṣe ọmọde yẹn (ọmọde yẹn ko mọ nkankan), ṣugbọn nitoripe oniwaasu kan lori pẹpẹ ti kuna lati duro lẹnu iṣẹ́ rẹ̀ ni. Bi o ṣe ri gan-an niyẹn. Dajudaju. Awọn obinrin yoo lọ soju popo, wọn yoo wọ aṣọ ti o n fa ọkunrin mọra ati iru awọn nkan bẹyẹn, awọn ẹlẹṣẹ yoo wo wọn, wọn ko si ni mọ wipe o ti jẹbi bi ẹni wipe o ti ba ọkunrin yẹn sùn ni. Jesu sọ bẹẹ! Jesu wipe, “Ẹnikẹni ti o ba wo obinrin lati ṣe ifẹkufẹ si i, o ti ba a ṣe panṣaga ninu ọkan rẹ̀ ná, yoo si jiyin fun-un lọjọ idajọ.” Hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa!

150 Mo mọ wipe ẹ ro wipe eniyan lile ni mi. Emi kò le! Arakunrin yin ni mo jẹ, mo fẹran yin.

151 Ẹ sá fun ibinu ti o n bọ! Ẹ lọ sibi agbelebu ki ẹ si sọkun titi ti ọkan yin yoo fi kun fun Ẹmi Rẹ, eyiti yoo kọ ẹyin yin si ohun gbogbo ti o jẹ ti aye, ti ẹ o si fi maa rin pẹlu iwa-bi-Ọlọrun niwaju Rẹ, ti ọkan yin yoo si gbinajẹ fun-Un. Ìfé ni! Ki i ṣe afipaṣe. Kristi ki i ṣe afipaṣe, lati sin Kristi, ifẹ ni a fi n sin Kristi. Yoo jẹ ẹrù wuwo fun ọ, yoo si rọ ọ́, titi ti gbogbo èémí rẹ yoo fi maa ba Tirẹ mu. Igba yẹn ni o to lee ri èṣẹ̀.

152 Ó sọkun sori aye. Ó ba Ọlọrun ninu jẹ ni ọjọ Noah, nigbati O ri ọkan awọn eniyan. Jesu joko sori oke, O ni, “Jerusalẹmu, Jerusalẹmu, Emi yoo ti radọ bo ọ pẹ tó, ṣugbọn wakati rẹ ti de, a si ti fi ile rẹ silẹ ni ahoro.”

153 Bẹẹ ni yoo ri nigbati Ọmọ Ọlọrun yoo de, ọkan onigbagbọ tootọ yoo bajẹ. O ti ri i nisisiyi wipe o yẹ ki isọji gba ilẹ yi kan. Bawo ni o ṣe lee ṣẹlẹ nipasẹ awọn ọmọ àlè? Bawo ni o ṣe lee ri bẹẹ, nigbati o jẹ wipe a ti da wọn lẹbi lati ilẹ wá?

154 Ijọba Ọlọrun dabi ẹniti o ju àwọn sinu odò, nigbati o fa a jade, o ni ijapa nla, ijapa kekere, ejo, ọ̀pọ̀lọ́, ati awọn ẹja diẹ. Ki i ṣe tirẹ lati pinnu èwo ni yoo jẹ́, o kan ṣaa ju u si bèbè odo ni. Ohun ti Ihinrere n ṣe niyẹn. Ohun ti Billy Graham, Oral Roberts, emi, ati awọn oniwaasu miran ti o n waasu Ihinrere n ṣe niyẹn, a o ju awọn sinu odò, a o si fa a jade sita, wipe, “Awọn niyẹn o, Oluwa.” Ṣugbọn kini a n ṣe ni gbogbo igba? A ri i wipe, ki a to pada de ibẹ, wọn tun ti pada sinu odò. Ki lo ṣẹlẹ? Lati ilẹ wá, ijapa nla ni. Iyẹn ko yi i pada, wipe a mu u sinu awọn Ihinrere. Ijapa nla ni lati ilẹ wá. Ijapa kekere ni lati ilẹ wá. Ejo ni lati ilẹ wá. Agabagebe ni ki o to wa sinu ijọ. Ko ni ifẹ lati fi ọti mimu ati tẹ́tẹ́ tita rẹ silẹ, ati siga mimu ati irọ pipa, ati ole jija. O kan wọle wa ni nitoripe o n bẹru ọrun-apaadi. O kan tun n sọ ara rẹ di ọmọ ọrun-apaadi si i ni, nigbati o ba ṣe bẹyẹn. Otitọ niyẹn. “Hiha ni ẹnu ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, awọn diẹ ni o si n rin-in.”

Ẹ jẹ ki a gbadura.

155 Oluwa, ṣe iwadi mi, Oluwa. Gba ọrọ mi yẹwo nisisiyi, Oluwa. Maṣe jẹ ki n wa sibi idajọ niwaju Rẹ, lẹyin ti mo ti waasu bi eyi tan. Ah, bi ohun àìmọ́ kan ba wà ninu mi, Oluwa, jọwọ mu u kuro! A ri ọjọ́ ti a n gbe ninu rẹ, nigbati awọn ọkunrin ati obinrin ti n gan. Oju n ti wọn. O sọ nigbakan pe, “Awọn ọmọbinrin Sioni ko tilẹ ni itiju.” Wọn ti mu iwa rere wọn kuro tobẹẹ ti wọn kò tilẹ tiju mọ́. Oluwa o, ronu nipa rẹ̀! Ti a si mọ wipe akoko n lọ, ni isẹ́ju kan tabi meji si i, iparun nla naa yoo de, nigbanaa, jẹ ki ẹniti o jẹ ẹlẹgbin maa jẹ ẹlẹgbin sibẹ.

156 Ọlọrun, sọ gbogbo wa jí ni owurọ yii. Mì wá tìtì, Oluwa! A ri i ti awọn àmì naa n farahan. Oju wa là lati mọ iyẹn. A ri ẹgbẹlẹgbẹ,

ẹgbẹlẹgbẹ, Oluwa, ti wọn kọ èyìn si i, ti wọn si lọ kuro. Mo n ro o wipe, kini mo lee ṣe, kini mo lee ṣe, Oluwa? Ohunkohun ha wà bí, Oluwa? Ti o ba jẹ wipe o yẹ ki n waasu si i ni, tabi ki n gbadura si i, tabi lati ṣe ohunkohun si i, ran mi lọwọ, Oluwa, ki n lee mu Iṣẹ́ Iranṣẹ naa to awọn eniyan lọ. Kini mo lee ṣe? Ṣugbọn wọn n kọ Ọ silẹ ni gbogbo igba. Iwọ n ṣe awọn iṣẹ́-ami nla Rẹ, O si n ṣe awọn iṣẹ́-àrà Rẹ, sibẹ, awọn eniyan n tẹsiwaju bakannaa. Ṣe Iwe Mimọ Rẹ fẹ di mimuṣẹ ni, ṣe akoko ti to ti o jẹ wipe, “Ko si ẹniti o lee wa sọdọ Mi bikoṣepe Baba Mi ba kọkọ fà á ná, gbogbo awọn ti Baba ti fi fun Mi yoo to Mi wa”? Oluwa Ọlọrun, jẹ ki awọn eniyan ji giri ni owuro yii, ki wọn si ri àmì ti o gbẹyin aye. Mo gbadura, Ọlọrun, wipe ki O fi nkankan fun awọn eniyan.

157 Bukun fun awọn eniyan kekere ti o wa nibi ni owuro yii. Ọlọrun, bẹrẹ pẹlu Arakunrin Neville, Oluwa. Wo ara rẹ sàn. O n ṣaisan ni owuro yii, Oluwa, inu rirun ni. Mo gbadura wipe ki ọwọ iwosan Rẹ wà lara rẹ̀. Ṣọ ọkan rẹ̀ jí.

158 Ọlọrun, jade lọ si aarin ijọ yii. Awọn ọkunrin ati obinrin wa nihin yii ti o jẹ wipe mo lee má ri wọn mọ titi di ọjọ naa nibi idajọ, nigbanaa, mo nilati jihin. Ṣugbọn mo ti ka Ọrọ Rẹ, “Hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa, awọn diẹ ni o si n rin-in.” Oluwa o, jẹ ki awọn wọnyi jẹ “diẹ” naa, awọn kan ninu wọn, ṣe Iwọ yoo ṣe bẹẹ, Oluwa? Gba bẹẹ fun gbogbo eniyan nibi yii.

159 Mo gbadura gẹgẹbi eniyan ṣe lee gbadura. Oluwa, awọn eniyan wọnyi yoo ṣe ohunkohun fun mi, lati lee ran mi lọwọ. Ti ebi ba n pa mi, wọn yoo fun mi ni ounjẹ. Ti mo ba nilo aṣọ, wọn yoo ra a. Wọn yoo parapọ lati ra ọkọ ayọ́kẹ́lẹ́ fun mi, lati waasu Ihinrere. Wọn yoo ṣe ohunkohun bẹẹn. Baba, ṣe iwadi ọkan wọn ni owuro yii, jọwọ ṣe bẹẹ, jẹ ki wọn ṣe iwadi rẹ̀ niwaju Rẹ. Emi ko mọ, mo gbagbọ wipe gbogbo wọn ni o wà ninu Ayanfẹ yẹn. Fi emi naa sibẹ pẹlu, Oluwa. Bi idi kan ba wa ninu mi ti n ko fi ni si nibẹ, Oluwa, Iwọ ṣaa fi han mi, emi yoo ṣe atunṣe rẹ̀ nisisiyi. Mo fẹ ni idaniloju, Oluwa, wipe ni owuro ọjọ́ yẹn, ki yoo si wahala leti odo naa. Mo fẹ lọ lọjọ yẹn. Emi ko si mọ igba ti iyẹn yoo jẹ, o lee jẹ oni. Nitorinaa, ran mi lọwọ lati mọ, ran awọn eniyan wọnyi lọwọ lati mọ.

160 Nigbati a ba si ri i wipe ọkan wa ṣe alaibikita! Ah, a gbadun lati feti si Iwaasu daradara lori ẹrọ redio, tabi lati lọ si ile-ijọsin. A fẹran Iwaasu ti o dara. A ko bikita lati sọrọ nipa Jesu nibikan. Ṣugbọn o, Oluwa, njẹ èṣè jẹ ẹrù wuwo fun wa bi, njẹ ó mu omijé ṣàn loju wa bi, njẹ a n kẹdun, njẹ a n sọkun, njẹ a si dide duro lodi si i, ani ohun gbogbo, awọn iwa irira ti o n ṣẹlẹ laarin ilu? Oluwa, jẹ ki Angẹli Ọlọrun ri iyẹn lara wa, ki o si ṣami si wa lara. Gba bẹẹ, Oluwa.

161 Maa bọ, Jesu Oluwa, nisisiyi, ki O pese ọkan wa silẹ, ki O si fun wa ni àmì Rẹ tootọ wipe Iwọ wa laarin wa, ki a lee mọ wipe awa n gba—n gba àmì ti o kẹyin ki iran yii to dopin.

162 A ri riru ofin, nibiti a ti ri awọn ọkunrin ti o n gbe orilẹ-ede yii, ti wọn ni ọmọ nipasẹ iyawo ẹlomiran, ati—ati awọn ọmọdebinrin loju popo, ọgọọgọrun ni o n kuro ni ile-iwe lọdọọdun, ti awọn ọdọbinrin si n di ìyá, bẹẹni ko si ọ̀wọ̀ kankan, awọn obinrin ti n di majele, funra wọn, nipa siga mimu ati—ati ọti mimu, ati tẹlifisan ati awọn nkan bẹẹ ti o n ba ọkan awọn ọmọde jẹ. Oluwa o, yoo ti duro pẹ to? Iwọ si niyi, Ọlọrun Mimọ ni Ọ!

163 Baba, mo—mo ni imọlara ajeji loni wipe a nilati ṣe nkankan kiakia, Oluwa. Emi ko mọ ohun ti mo lee sọ, ṣugbọn mo gbadura, Oluwa, wipe ki O fi ohun ti o yẹ ki a ṣe sinu ọkan wa. Gba awọn nkan wọnyi, Oluwa. A beere wọn ni Orukọ Jesu. Amin.

164 Wakati naa ti de. Gbogbo ọlọgbọn eniyan ti o ni ọpọlọ, ni o mọ wipe nkankan n fẹ ṣẹlẹ. Ko si ẹnikan ninu ile yii, ti ori rẹ pé, ti kò mọ wipe aye yii ko lee duro titi ni ipo ti o wa yii.

A ko lee duro, ẹyin ọ̀rẹ́. Ko si ohun kan, gẹgẹbi oluṣọ-aguntan yin ati arakunrin yin, ko si ohun kan ti mo lee dari yin si ni owurọ yii bikoṣe Jesu Kristi. Ko si ohun kan ti mo mọ. Ẹ ṣaa ronu awọn nkan ti a ti sọtẹlẹ wipe yoo ṣẹlẹ ki Igbasoke to ṣẹlẹ, ohun gbogbo ti mo mọ ni a ti mu ṣẹ.

165 O lee sọ pe, “Ami ẹranko naa nkọ?” Iyẹn yoo ṣẹlẹ nigba Ipọnju. Ijọ yoo ti lọ nigbanaa. A ki yoo sàmì si awọn wọnyi, awọn wọnyi yoo ti lọ, ṣe o ye yin. Gbigba ami naa ti n lọ lọwọ bayi. Gbigba ami naa ni ifarahan, ìsàmì sí. Sá lọ sọdọ Ọlọrun, sá lọ sọdọ Rẹ̀ kiakia!

166 Nko mọ ni owurọ yii, bi a ṣe duro sibi yii fun iṣẹ́ju kan. Mo n ronu bi ẹyin naa ṣe n ronu. Mo—mo mọ ohun ti ẹ n ro, ẹnikọọkan yin n gbiyanju lati ronu wipe, “Ọlọrun o, wa mi ri!” Bi o ṣe ri lara temi naa niyẹn. Mo mọ wipe awọn Iṣẹ́-iranṣẹ Iwaasu yii, ọrẹ, ko gbajumọ laarin awọn eniyan. Ti o ba da wọn lẹbi, o…o…o ti rẹ̀ wọn silẹ niyẹn. Ẹnikan nilati ṣe iyẹn. O wu mi ki o jẹ ẹlomiran. Ṣugbọn ti o ba jẹ ojuṣe temi lati ṣe e, ti mo ba nilati jẹ obinrin ti o n nu ilẹ, jẹ ki n maa nu ilẹ. Ti mo ba…Dafidi wipe, “O sàn ki n jẹ ẹní ìnùsẹ̀ ninu Ile Ọlọrun, ju ati gbe inu àgọ́ pẹlu ẹ̀ṣẹ̀.” Bẹẹ ni. Ohunkohun ti Ọlọrun ba fẹ ki o ṣe, ṣe e. Maṣe tiju. Bi ohun kan ba wà…

167 Ẹ si ranti, mo mọ wipe nkan nla niyẹn. O ní, “Arakunrin Branham, o sọ wipe ọkan mẹjọ pere ni a o gbala?”

168 Emi ko mọ iye awọn ti a o gbala, emi ko lee sọ fun yin. Ṣugbọn kini kan ni mo sọ: wọn yoo kere jọjọ, ni iru ọjọ oni yii. Ẹ ro o wo, ni ọjọ yẹn ti Oun wà nibẹ, ẹni melo ni a gbala. Ẹ ronu nipa ọjọ Noah, ati

ọjọ Lọọti—Lọọti, ati gbogbo wọn, Ó ni, “Bẹẹ ni yoo ri nigbati Ọmọ eniyan yoo de, nitoripe, hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa.” Ṣe ẹ mọ, o nilati danikan wọle funra rẹ, pẹlu Oun, ko ju bẹẹ lọ. Ṣe o ye yin? “Awọn diẹ ni o si n rin-in.” Ẹni melo ni o gbagbọ wipe Otitọ Ihinrere niyẹn? Jesu Kristi sọ bẹẹ, “Awọn diẹ ni yoo rin-in.” Awọn diẹ péréte. Iwọ jẹ ọkan ninu awọn diẹ yẹn. Mo mọ wipe ó le, o gba agbara. O le fun emi naa lati sọ ọ, nitori ifẹ eniyan ti mo ni si yin, ṣugbọn ifẹ Ọlọrun ni o n rò mi lati sọ fun yin.

169 Ni bayi, Ẹmi Mimọ kannaa ti o ṣiṣẹ ni ọjọ Abrahamu, ti o ṣiṣẹ ni ọjọ Kristi, ni a ṣe ileri wipe yoo wà nibi lati ṣe nkan kannaa. Ó wà nibi. Ti o ba jẹ wipe Otitọ ni mo ti sọ fun yin, Ọlọrun yoo ti Otitọ naa leyin.

170 Ti emi ko ba tẹle ọrọ mi, emi ki i ṣe ẹniti o n mu ọrọ mi ṣẹ. Ti iwọ naa ko ba tẹle ọrọ rẹ, iwọ ki i ṣe ẹniti o n mu ọrọ rẹ ṣẹ. Ni bayi, mo lee ṣe ileri nkankan fun ọ, ti n ko si ni lee ṣe e, ṣugbọn—ṣugbọn emi yoo wa sọ fun ọ. Ti mo ba jẹ ọ ni gbèsè ohun kan, ti mo si n sapamọ fun ọ, a jẹ wipe agabagebe ni mi. Ti mo ba wa sọ fun ọ wipe, “Mo jẹ ọ ni gbèsè, ṣugbọn n ko tii lee san-an bayi, ṣugbọn emi yoo sa gbogbo ipa mi,” iwọ yoo dariji mi, iwọ yoo si ran mi lọwọ. Ṣe o ye yin?

171 Gbogbo wa ni a jẹ Ọlọrun ni gbese ohun kan. A jẹ Ẹ ni gbese aye wa. Ẹ jẹ ki a sọ otitọ nipa rẹ̀. Jade sita ki o si wipe…Maṣe sọ pe, “O dara, wo o, mo jẹ́—mo jẹ́ ọmọ Ijọ Alagba. Mo jẹ ọmọ Ijọ Eleto. Mo jẹ ọmọ Ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ. Mo jẹ ọmọ Ijọ Ọlọrun. Mo jẹ ọmọ Ijọ Oniwa Mimọ. Mo jẹ ọmọ Ijọ Arinrinajo Mimọ.” Maṣe ronu bẹyẹn! Ẹgbẹlẹgbẹ awọn wọnyẹn ni yoo wà ni ọrun apaadi. Iwọ ṣaa jẹ Kristẹni, ninu Kristi.

172 Ẹni melo ni yoo sọ pe, “Arakunrin Branham, ranti mi ninu adura bayi, mo fẹ dide diduro”? Ki Ọlọrun bukun fun yin.

173 Oluwa, O ri ọwọ wọn. Wakati naa ti de, Ẹmi Mimọ nla naa ti mu ki ilé yii dakẹ jẹẹ ni owuro yii. Mo ni imọlara Ifarahan Rẹ. Mo mọ wipe Iwọ wà nibi lati bu ọla fun Ọrọ Rẹ, “Èmi Oluwa ni o ti gbin-in, Emi yoo si bomi rin-in tọsan-toru, ki ẹnikẹni ma baa gba a lọwọ Mi.” O ran Ọrọ Rẹ jade lati ṣe iṣẹ́ kan pàtó, Oun yoo si—Oun yoo si ṣe bẹẹ, Oluwa. Iwe Mimọ sọ pe ọkannaa ni Ọ lana, loni, ati titi lae.

174 Wọn ko lee gbagbọ, awọn eniyan ọjọ Rẹ ko lee gbagbọ wipe Ẹmi Mimọ wà ninu Rẹ. O si sọ ara Rẹ (ti o jẹ Eniyan) di Ọlọrun, eyiti o jẹ wipe, Iwọ ni Ọmọ Ọlọrun ti a ti ipasẹ wundia bi, ti o wa si aye lati ra wa pada kuro ninu ẹṣẹ̀ wa. Ati nitoripe wọn ri Ẹmi Ọlọrun ninu Rẹ, wọn gbiyanju lati ya a sọ́tọ̀. O si sọ fun wọn, Oluwa, “Ki i ṣe Emi ni o n ṣe awọn iṣẹ́ naa, Baba Mi ti o n gbe inu Mi ni. Oun ni o n ṣe awọn iṣẹ́ naa. Ti ẹ ba pe Abrahamu ni ‘baba’ yin. Abrahamu ri ọjọ

Mi." Dajudaju, o ri i, nigbati o duro sọdọ Rẹ̀, ti o ri I ti O ṣe awọn iṣẹ́ ati àmì yẹn. "O ri ọjọ Mi, o si yọ̀." O ni, "Ẹ kuna, nitoriti ẹ kò mọ Iwe Mimọ tabi Agbara Ọlọrun, bi Ọlọrun ṣe lee ṣiji bo wundia, ki o si bi Ọmọkunrin kan (nipasẹ ibi wundia) ti O si funra Rẹ gbe ninu ẹkunrẹrẹ Agbara Rẹ̀, ninu Ọkunrin kan yẹn."

175 Ati bi O ṣe mu Ẹjẹ kannaa ninu Ara kannaa ti O fi ṣe Irubọ, ti O ya awọn eniyan kan si mimọ, ki Oun funra Rẹ̀ lee maa gbe inu wọn, ki wọn lee mu iṣẹ́ Rẹ̀ tẹsiwaju titi de opin! Ọlọrun o, ṣọ awọn eniyan jí lati ri iyẹn. Gba bẹẹ. Gba gbogbo awọn ti o na ọwọ soke là. Wẹ ọkan wọn mọ́. Oluwa, ọwọ mi wa loke. Oluwa o, wẹ mi mọ. Ile itọnisọna ni eleyi. Ibi yii ni o ti yẹ ki a wẹ̀ wá. Jẹ ki Ẹmi Mimọ wẹ̀ wá ni owuro yii, ki O si fọ̀ wa mọ kuro ninu idibajẹ.

176 A gbadura, Oluwa, wipe ẹnikẹni ki yoo fi ibi yii silẹ lai kun fun Ẹmi Rẹ. Boya isọyigi ara ti a lee foju ri kan ki yoo sí nigbati ó bá ṣẹlẹ. Ṣugbọn, Oluwa, wọ inu lọ, ṣí igbá inu wa, ki O si fi ohun ti a jẹ́ hàn wá, Oluwa. Gba bẹẹ. Lẹyinnaa, fi Ẹmi Rẹ kun wa, pẹlu ọkan otitọ ti ó mọ́. Ni àkókò inunibini ati idanwo lile wọnyi, Iwọ yoo maa dun mọ wa si i pẹlu ifẹ bi a ṣe n rin lọ, ti a si n duro de ọjọ naa. Bi omije ti n ṣan ni ẹ̀rẹ̀kẹ́ wa, fun ẹ̀ṣẹ̀ ilu yii, jẹ ki Ẹmi Mimọ boju wolẹ, ki O si wipe, "Ẹnikan niyẹn ti Mo lee ṣe ami si, Temi ni ọkunrin naa, Temi ni obinrin naa." Gba bẹẹ, Oluwa. Jẹ ki a ri i laarin wa loni. A beere rẹ ni Orukọ Jesu. Amin.

Nigbati mo ba de eti odo ni opin ọjọ,
T'afẹfẹ 'banujẹ si ti fẹ,
Ẹnikan yoo duro, ti yoo f'ọna han mi,
N ki yoo nikan la Jọrdani ja.

N ki yoo nikan la Jọrdani ja,
Jesu ku f'etutu ẹ̀ṣẹ̀ mi;
Gbati mo ba r'okunkun, Oun yoo duro de mi,
N ki yoo nikan la Jọrdani ja.

177 Mọ fẹ mọ Ọ nisisiyi. Mu ọwọ mi, Oluwa ọ̀wọ́n, maa tọ mi lọ, jẹ ki n duro. Jẹ ki n duro nihin yii, Oluwa, lodi si ohun gbogbo ti o kuna, ohun gbogbo ti o jọ ikuna. Emi ko bikita ohun ti ẹnikẹni sọ, jẹ ki n duro, Oluwa. Nigbati mo ba ti ṣe gbogbo ohun ti mo lee ṣe, ràn mi lọwọ lati duro. Mu ọwọ mi ki O si mu mi la a ja, Oluwa. Ṣe nkankan, jẹ ki n duro. Nigbati awọn nkan wọnni ba de, ati awọn ọrọ̀ aye yii, ati gbogbo ẹwà ati ogo rẹ̀; fọ́ oju mi si i, jẹ ki n ri Oun nikan, ani Ẹniti o kú fun mi. Ti ó ba nilati gba gbogbo ọ̀rẹ́ mi lọwọ mi, ti o ba nilati gba ohun gbogbo ti mo ni lọwọ mi; iyẹn ko jẹ nkankan, mo jọwọ gbogbo rẹ sibi pẹpẹ. Bẹẹ ni, jẹ ki n duro gẹgẹbi olootọ. Lọjọ kan, nigbati afẹfẹ ba fẹ si mi loju, ti mo si mọ wipe ọkàn mi kò ṣiṣẹ mọ, ti ọjọ mi ti tán, ti akoko mi ti tó, ti a si mu kaadi mi kuro lori pẹpẹ, n kò fẹ nikan la

Jọrdani já. Oun yoo wà nibẹ. Bẹẹni. Nigbati mo ba ri okunkun, Oun yoo duro de mi nibẹ, n ki yoo nikan la Jọrdani já. Ti mo ba duro fun Oun nisisiyi, Oun yoo duro fun mi nigbanaa. Emi yoo gbe igbe-aye mi fun Ẹniti o ku fun mi, aye mi yoo ti layọ tó nigbanaa. Bi mo ṣe fẹ duro niyẹn.

178 Mo lero wipe awọn alaisan wà nibi yii. Ṣe wọn pin kaadi kankan? Mo gbagbe. Ṣe wọn pin kaadi? Njẹ wọn fi kaadi kankan sita? Ẹnikẹni ha ni kaadi adura bi? Rara.

179 Mo n duro de Ẹmi Mimọ. Ti ẹ ba ṣaa lee gbagbọ, ẹ ṣaa ni igbagbọ, ẹ maṣe ṣiyemeji. Ti Ọlọrun yoo ba fi iṣoro yin han mi…Ohun yoowu ti o jẹ, emi ko mọ̀; ti o ba lee na ọwọ rẹ soke, wipe iwọ ko mọ mí, emi ko mọ ọ́. Njẹ ti Ọlọrun ba fihan nibi yii, ṣe iwọ yoo gbagbọ wipe Angẹli kannaa ti o mu Iṣẹ́-iransẹ wa ṣaaju iparun nigbayẹn, yoo jẹ Angẹli kannaa ti o n mu u wa nisisiyi ṣaaju iparun miran. Ṣe ẹ o gba iyẹn gbọ? Ti ẹ o ba ṣe bẹẹ, ẹ na ọwọ yin soke. O dara. O dara, ki Oluwa gba bẹẹ.

180 Ó joko si ẹgbẹ mi. Ẹnikan tun wà ti o joko si ẹgbẹ mi, iyẹn ni Arabinrin Snyder yii, tabi Arabinrin Murphy, ni orukọ rẹ̀, ti o joko sibi yii. Mo mọ wọn.

181 Emi ko mọ ọkunrin yii, alejo ni o jẹ si mi. Ṣugbọn Ọlọrun mọ ọ. Ti Ọlọrun yoo ba fihan nisisiyi, melo ninu yin ni o mọ wipe ki i ṣe…

182 Ẹ maṣe wo èmi. Kai, ara oko Kentucky ni emi, ti o ba jẹ ti iyẹn ni. Emi—emi kò tilẹ ka iwe tó, iwe ti ó tó, lati—lati kọ orukọ ara mi. Ṣugbọn kini kan ni mo mọ, mo mọ Oun. Iyẹn ni, iyẹn ni—gbogbo ohun ti mo fẹ mọ niyẹn. Ni bayi, ẹ maṣe—ẹ maṣe wo ede oyinbo mi.

183 Ẹ lee ro wipe iwaasu mi owuro yii kò dán mọ́rán tó, ati ohun gbogbo, ẹyin ẹ fi we Bibeli wo lẹẹkan, ki ẹ wa wo o boya kò lọ deedee. Ẹ wo o boya awò oju yin kò ni lọ taara nigbati ẹ—nigbati ẹ ba fi sibẹ. Ẹ maṣe fi we èrò ti ara yin, ṣugbọn ẹ fi we ohun ti Oun sọ. “Hiha ni ẹnu-na naa, tooro si ni oju ọna naa, awọn diẹ ni o si n rin-in; nitori gbooro ni ọna naa ti o lọ si iparun, onibu si ni ẹnu-ọna naa, ọpọ si ni awọn ti o n ba ibẹ wọle,” ẹgbẹlẹgbẹ lọna ẹgbẹlẹgbẹ ni yoo wọ ibẹ. Boya ẹnikanṣoṣo ninu ẹgbẹlẹgbẹ ni yoo wá. Bi o ṣe ri niyẹn. Ohun ti O sọ niyẹn. Oun kò sọ iye kan, ṣugbọn Ó wipe, “Bi o ṣe ri ni ọjọ Noah, ọkàn mẹjọ pere. Bi o ṣe ri ni ọjọ Sodomu, mẹta.” Ninu gbogbo wọn, awọn mẹta ni a gbala, nipa ina. Bẹẹ ni yoo ri!

184 Ni bayi, bi ẹnikẹni ba jẹ ẹni èmí gidigidi, mo fẹ ki ẹ wo ọkunrin ti o joko sibi yii, ó kan n wo mi ṣaa ni. O na ọwọ rẹ̀ soke, emi ko mọ ọ́; emi ko ri i ri, n ko si mọ ohunkohun nipa rẹ̀. Ó kan ṣaa joko sibẹ, o si n wo mi. Ṣugbọn, ẹ wo o, o n fọwọ kan nkankan, o n gbadura. Otitọ niyẹn. Njẹ bi Oluwa yoo ba sọ fun mi…Ibiti ọkunrin yẹn joko

si jinna si mi, igba ti a o si kọ́kọ́ jọ pade niyi, oun si joko si ibẹyẹn. Ti Oluwa yoo ba fi han mi ohun ti o—ohun ti o…emi—emi ko lee wò ó sàn. Emi ko ṣe bẹẹ, emi ko lee ṣe iyẹn, nitoripe Ọlọrun ti ṣe iyẹn pari na. Ṣugbọn yoo fi kun igbagbọ rẹ̀. Gbogbo yin ẹ wò bayi, Oun ti wa nibi, ani Ẹmi kannaa. Ẹ si ranti, Jesu ṣe ileri eyi, ṣaaju igba ikẹyin. Oun ni àmì ti o maa n kẹyin nigbagbogbo.

185 Ni ijelo, emi ati Leo joko loju pópó, àwa kan si n sọrọ. Mo bẹrẹ sí ní imọlara wipe iyipada kan n bọ, iyipada kan n bọ. Nigbati a sọrọ nipa rẹ̀, ki yoo jẹ iyipada ninu iṣẹ́-iriju iwaasu mi, nitoripe ko lee goke ju bẹyẹn lọ, ṣugbọn yoo jẹ iyipada nipa emi takarami. Mo ti maa n jẹ alailera tẹlẹ, ti mo si n gba awọn eniyan laaye lati maa dari mi, ati lati tọ́ mi sọna, ti wọn si n ran mi lọ *sihin* ati lọ *sọhun*. Iba ṣe wipe mo ti ṣe ohun ti Oluwa sọ wipe ki n ṣe lati igba pipẹ wa ni, emi ki yoo si ninu iṣoro ti mo wà loni. Mo n jade lọ ni ọ̀sẹ̀ ti o n bọ yii lati danikan wà pẹlu Ọlọrun. Bẹẹni, sà. Mo—mo nilati gbọ lati Ọrun wá. Emi ko fẹ lati jẹ alailera, mo fẹ duro lori idaniloju temi.

186 Ọkunrin yii, O ṣaa n pada si ọdọ rẹ ni, o joko si ẹyin, nitoripe ọkunrin yẹn n gbagbọ, o n gbagbọ nitootọ. Mo n wo gbogbo ijọ kaakiri, O si n pada wa sọdọ ọkunrin naa taara. Ó ṣe alaini, ọkàn rẹ wuwo, ṣugbọn ẹlomiran ni ọkan rẹ wuwo fun. Bẹẹ ni. Ẹlomiran ni o n gbadura fun. Ẹnikan wà ni ọkan rẹ̀. Bẹẹ ni, tabi bẹẹ kọ? Ọ̀rẹ́ rẹ̀ kan ni. Ti mo ba sọ ohun ti o n ṣe ọ̀rẹ́ yẹn fun ọ, ṣe iwọ yoo gba mi gbọ wipe mo jẹ iranṣẹ Ọlọrun? Ọti amupara ni. Bẹẹ ni. Ti o ba ri bẹẹ, na ọwọ rẹ soke.

187 Ṣe ẹ gbagbọ? Ẹnikan wa nibi yii ti o na ọwọ rẹ̀ soke, obinrin kan ni ẹyin ibi yii, ẹnikan. Bẹẹni. Bẹẹni. Ṣe iwọ ko mọ mi? Ṣe alejo ni mo jẹ si gbogbo yin? Emi ko mọ́ ọ́, ṣugbọn Ọlọrun mọ́ ọ́. Ṣe o gba iyẹn gbọ? Ti Ọlọrun ba fi ohun ti o wa lọkan rẹ hàn mí, ṣe iwọ yoo gba mi gbọ wipe mo jẹ iranṣẹ Rẹ̀? Arabinrin, ohun ti o n daamu rẹ ni ọmọde ti o wà nibẹyẹn. Bẹẹ ni. Ọmọde yẹn ni egbò ni oju rẹ. Dokita ko lee ṣe ohunkohun nipa rẹ. Alejo ni ẹ jẹ nibi, iwọ ati olufẹ rẹ ti ó joko si ibẹyẹn Ṣe ẹ gbagbọ wipe Ọlọrun lee sọ ẹniti ẹ jẹ fun mi, tabi ibiti ẹ ti wá? Ṣe ẹ gba a gbọ? Ṣe ẹ o gba iwosan ọmọde naa ti Ó bá ṣe bẹẹ? [Arabinrin naa sọ pe, “Bẹẹni.”—Onkọwe.] Ko buru, ẹ lee pada si Somerset, Kentucky, nibiti ẹ ti wa, ki ẹ si gbagbọ wipe Oun yoo mu u lara da, ki ẹ si gbagbọ wipe egbò naa yoo fi ọmọ naa silẹ, ti ẹ ba lee gba a gbọ.

188 Nigbati mo sọ ọrọ yẹn, ẹnikan ti o naro si ẹyin ile nibẹyẹn, lati Somerset, Kentucky, n gbadura, pẹlu aisan ọkàn. Ṣe ẹ gbagbọ wipe Ọlọrun yoo mu wọn lara da? Ti ẹ ba gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan yin, ki ẹ si gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wòsàn, yoo si mu ni lara da.

189 Nibi yii, nibi yii, mo gbagbọ wipe ẹnikan na ọwọ soke nibi yii, nibi yii, obinrin kan ni. Bẹẹni, mo ri ọwọ rẹ. Ṣe alejo ni mo jẹ si ọ, arabinrin? Emi ko mọ ọ́. A kò pàdé rí. Ṣe o gba mi gbọ wipe mo jẹ iranṣẹ Rẹ̀? [Arabinrin naa sọ pe, "Bẹẹni."—Onkọwe.] O gbagbọ? O ni ẹrù wuwo kan ni ọkàn rẹ, tabi nkankan. Ṣe o gbagbọ wipe ti Ọlọrun ba lee fi han mi, ṣe o gbagbọ wipe Ẹmi kannaa ti o wà ninu Kristi ni? Ọkọ rẹ ti o joko si ibẹyẹn, gba nkan kannaa gbọ pẹlu? Ṣe iwọ yoo gba nkan kannaa gbọ? Ọ̀rọ̀ nipa ọmọdebinrin yin ti o joko si ẹgbẹ yin nibẹyẹn ni. Bẹẹ ni, o ni arun jẹjẹrẹ. Ṣugbọn ṣe ẹ gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wò ó sàn? Ti ẹ ba gbagbọ, ẹ na ọwọ yin soke. O dara, ẹ gbe ọwọ yin le ọmọ naa.

190 Jesu Oluwa, ni Iwaju Ẹmi Rẹ, mo fi èṣù ti o n pa ọmọde yii bú. Nipa igbagbọ, mo fi Ẹjẹ Jesu Kristi si aarin apaniyan yẹn ati ọmọde yii. Jẹ ki o yè. Amin.

191 Ẹ ni igbagbọ ninu Ọlọrun. Ẹ maṣe ṣiyemeji. "Bi iwọ ba lee gbagbọ, ohun gbogbo lo ṣee ṣe." Bi iwọ ba lee gbagbọ, ohun gbogbo lo ṣee ṣe. Otitọ ni.

192 Ẹnikan leyin ibẹyẹn tun na ọwọ rẹ̀ soke, nibikan, iwọ, arabinrin ti o wa ni ẹyin yẹn. Ṣe o gbagbọ wipe iranṣẹ Ọlọrun ni mi? Emi ko mọ ó, iwọ naa kò mọ mi. Ṣe o gbagbọ wipe Ọlọrun lee fi iṣoro rẹ han mi? Ṣe iwọ yoo gba Jesu gẹgẹbi Oluwosan tabi Olupese rẹ, ohun yoowu ti ó jẹ—ohun yoowu ti o jẹ…? Ṣe o gbagbọ nigbanaa? O dara, a jẹ wipe ara aibalẹ ti o ní yẹn, ohun ti o ni tẹlẹ niyẹn. Ti ó bá rí bẹẹ, dide duro lori ẹsẹ̀ rẹ, ti o ba ri bẹẹ, ki awọn eniyan lee ri i wipe otitọ ni. O dara, yoo fi ọ silẹ bayi. Maa lọ si ile, ki ara rẹ si dá. Ki Ọlọrun bukun fun ọ.

Kentucky ni iwọ naa ti wá. Uh-huh, Bẹẹ ni.

193 Obinrin ti o joko si ẹgbẹ rẹ naa wá lati Kentucky. Ibẹ̀ ni oun naa ti wá. Emi ko mọ ọ́, tabi bẹẹkọ? Ṣugbọn mo lee sọ fun ọ wipe nkankan n ṣe ọ. Ti mo ba lee sọ ohun ti o n ṣe ọ fun ọ, ṣe iwọ yoo gba Kristi gẹgẹbi Oluwosan rẹ? Inu itan rẹ ni. Ti o ba ri bẹẹ, na ọwọ rẹ soke, naa soke daradara ki awọn eniyan lee ri i. O dara, maa lọ si ilé bayi, yoo fi ọ silẹ. Igbagbọ rẹ mu ọ lara dá.

Mo pe yin nija wipe ki ẹ gbagbọ. Mo pe igbagbọ yin nija lati gbagbọ.

194 Obinrin kan joko sibi yii, o n gbadura, o fi aṣọ ilewọ rẹ bo oju rẹ. Emi ko mọ ọ́. Ọlọrun mọ ọ́. Joliet ni o ti wá, ni Illinois, o si ni eéwo. Otitọ niyẹn. Ó lee maa ya ọ lẹnu…(Bẹẹni, ohun ti—obinrin ti Rosella mu wa niyẹn. Bẹẹ ni. Ẹ duro na, o sọ fun mi nipa iyẹn, ṣugbọn ko mọ wipe n kò mọ obinrin naa ri. Bẹẹ ni. O kan ṣẹlẹ wipe igbagbọ obinrin naa pọ ni.) Emi yoo sọ nkankan fun ọ, ti o—o mọ wipe n kò mọ. O n

gbadura fun ọmọde ti o joko si opin ijoko yẹn, ti aisan n ṣe. Ọmọ rẹ niyẹn. Bẹẹ ni. Amin. O mọ wipe n ko mọ iyẹn.

195 Oun niyẹn, Ẹmi Mimọ ni! Ṣe o gba A gbọ? Ṣe o gba A? Njẹ ti o ba ri bẹẹ, ohun ti mo sọ nipa "hiha ni ẹnu-ọna naa, tooro si ni oju ọna naa" jẹ otitọ. Jesu Kristi, Ọmọ Ọlọrun, wà nibi nisisiyi. Ẹmi Ọlọrun alaaye wà nibi. Ṣe ẹ gba A gbọ? Njẹ ki ẹ lee mọ wipe emi ko jẹ nkankan lati wo ni sàn, emi ki i ṣe oluwosan, ṣugbọn Ẹmi Ọlọrun kan yàn mi lati fi ara Rẹ han ni. Emi kò kawe. Emi kò ni imọ ohunkohun. Ṣugbọn Ẹmi Rẹ ni o n ṣe e, ṣe o ye yin, O si fẹ ki ẹ mọ wipe otitọ ni mo sọ fun yin.

196 Otitọ niyi, wipe Jesu Kristi ti mu gbogbo yin lara da nisisiyi, ti ẹ ba lee gba iyẹn gbọ. Ni bayi, gẹgẹbi…Ti ó bá ṣiṣẹ́ ni Kingston, eyiti awọn akiriwaasu, tabi ẹnikẹni ti o wà lẹyin nibẹyẹn, ri i ti o ṣiṣẹ́ ni Kingston, nipa mimu ẹgbẹẹgbẹrun lara dá, eeṣe ti ki yoo fi ṣiṣẹ ni orilẹ-ede Amẹrika nibi, nibiti a ti ni bi o ṣe ri bayi? Eeṣe ti a kò fi lee gba a gbọ? Nitoripe a kò lee ré odò kekere yẹn kọja ni. Ṣe e gba a gbọ? Ẹ na ọwọ yin soke.

197 Ni bayi, awọn ọwọ yẹn kannaa, ẹ gbe e le ẹnikan ti o wa lẹgbẹ yin, ẹ jẹ ki n gbadura fun ẹni yẹn lati ibi yii, ki ẹ má sì ṣe iyemeji ni ọkan yin mọ, eyi yoo fi opin si i.

198 Kai, Arakunrin Neville! O wu mi, mo si ti gbadura, mo ti…Ẹ lee ro wipe ori mi ti daru; ko ri bẹẹ. Mo mọ ibiti mo wa. Iba ṣe wipe mo lee jẹ ki ẹ ri kini kekere yii! Njẹ ẹ mọ wipe Jesu Kristi, Ọmọ Ọlọrun, wà laarin awọn eniyan nibi ni owuro yii, nisisiyi, lọwọlọwọ bayi, O si n fi ara Rẹ han?

O lee sọ pe, o dara, "Arakunrin Branham, *iwọ* ni o sọ bẹẹ o."

199 Bawo ni mo ṣe sọ ọ? Emi kò mọ ọ. Obinrin miran wà ti o ni ikọ́ àwúgbẹ. A ti wo ọ san, arabinrin. Ibukun ni fun ọ. Gbọ mi, o n gbadura fun obinrin kan ti o ni ikọ àwúgbẹ, obinrin ti irun ori rẹ ti funfun ni. Bẹẹ ni. O dara, gba a gbọ. O dara. Ó wà nihin. Ifarahan Rẹ ni.

200 Ni bayi, ohun ti Ó sọ niyi, "Ami wọnyi ni yoo maa ba awọn ti o gbagbọ lọ. Ti wọn ba gbe ọwọ wọn le alaisan, ara wọn yoo dá." Bawo ni Ó ṣe lee parọ? Wo o, ko si ni ọwọ Rẹ, ko si ni ọwọ mi, ọwọ rẹ ni o kù sí. Ẹ gbagbọ bayi.

201 Mo n wo obinrin kekere kan ti o joko si ẹyin nibẹyẹn nisisiyi, o ni igbagbọ pupọ. Oun ati ọkọ rẹ ṣẹṣẹ wá sọdọ Oluwa ni. Ó joko sinu ipade yii, nkankan ti fọ́ sinu rẹ, eyiti dokita fẹ ṣe iṣẹ́-abẹ le lori laipẹ, o si ti fẹrẹ bi ọmọ. Dokita fẹ ṣe iṣẹ́-abẹ lẹyin iyẹn, ṣugbọn o bi ọmọ naa, wọn ko si ri ìju naa mọ. Ó ti lọ. Ṣe o ye yin? Kini idi? O kan joko bii…Ko goke wá sibi pẹpẹ rara. O kan joko si ẹyin nibẹyẹn, o si gba

a gbọ. Ṣe bẹẹ ni, Arabinrin Green, mo gbagbọ wipe orukọ rẹ niyẹn, iwọ ti o wà lẹyin nibẹyẹn? Bẹẹ ni. Ṣe ẹ ri ọwọ rẹ? Dokita ko tilẹ ri ohun ti ó fọ́ sinu rẹ yẹn mọ, gbogbo rẹ ti lọ. Kini idi? O gba a gbọ, o kan ṣaa jade sita, o si wipe, “Otitọ ni!”

202 Iwọ naa ṣe bẹẹ, gbogbo ipọnju ti o ni nilati kuro. Ọlọrun, Ẹniti o lee—Ẹniti o lee fi Nkankan ranṣẹ sinu ara eniyan, titi kan oju eyín ejò ti o wa ninu ẹsẹ ọkunrin yẹn, ani oró naa, ti o fẹ́ pa a, ti o si lee da a duro, ti o si pa a loju kan nibẹ, melomelo ni O lee pa awọn aisan ti o wa lara rẹ. Nitoripe ọkunrin yẹn wa ninu inira, o si nilo iranlọwọ. A nilati ran iwọ naa lọwọ pẹlu. Ti o ko ba ri iranlọwọ naa, iwọ yoo kú.

203 Ni bayi, ẹ gbe ọwọ yin le ara yin. Maṣe gbadura fun ara rẹ, iwọ gbadura fun ẹniti o wa lẹgbẹ rẹ. Iwa Kristẹni niyẹn.

204 Ẹ kọ ẹ̀kọ́ yii, ẹ kọ ẹ̀kọ́ yii, wipe, bi ẹ ba ti ṣe si awọn ẹlomiran, Kristi ni ẹ n ṣe bẹẹ si. Ti o ba ṣe rere fun ẹlomiran, Kristi ni o n ṣe rere si. Ti o ba ṣe ẹlomiran ni iṣekuṣe, Kristi ni o n ṣe ni iṣekuṣe. Kai!

205 Ah, mba lee jẹ ki eyi wọ inu awọn eniyan, iba ṣe wipe mo lee jẹ ki awọn eniyan ri i, ani ohun ti mo n wò, ati ohun ti mo ni imọlara rẹ̀, ati ohun ti mo mọ wipe o n ṣẹlẹ lọwọlọwọ bayi, ṣe ẹ ri i. Gẹgẹbi Kristi ṣe n gbiyanju lẹyin Iṣẹ́-iranṣẹ owuro yii, lati wọ inu ọkàn awọn eniyan lọ, ki Ó sì dá nkankan sibẹ; ki i ṣe yíyá gágá ara, ki i ṣe ìsọyìgì ara (ara rẹ̀ naa ni), ṣugbọn lati dá igbagbọ aiku kan sibẹ, ti ki yoo wipe, ti ki yoo fun ọta ni ínṣì kan.

206 Ni bayi, Oun yoo gbọ adura mi, Oun yoo gbọ tirẹ naa. Ẹ gbadura fun ara yin nisisiyi, bi emi yoo ṣe gbadura fun gbogbo yin.

207 Oluwa o, ni akoko alagbara nla yii, a mọ wipe eyi yoo jẹ iyatọ laarin iku ati iye, fun ọpọlọpọ. Mo n wariri ni Iwaju Rẹ, nitori mo mọ, Oluwa Ọlọrun, wipe mo gbọdọ fi gbogbo ọkan mi gbadura. Mo mọ wipe ó tilẹ ṣee ṣe ki ó maṣe sí alaisan kan laarin wa mọ ni iṣẹ́ju marun si i, ki gbogbo eniyan ti o wà nibi lee mọ wipe Iwọ wà nihin. Wọn dide duro ni owuro yii, Oluwa. Jẹ ki awọn eniyan nawọ soke, awọn ti wọn mọ wipe n kò mọ̀ wọn, ati wipe n kò mọ nkankan nipa wọn. Ṣugbọn Ẹmi Rẹ mọ wọn. Iwọ mọ aṣiri ọkan wọn, melomelo ni O mọ isoro ati ijiya wọn! Nitorinaa, Oluwa, jẹ ki o ṣẹlẹ loni, jẹ ki o ṣẹlẹ nisisiyi wipe Ẹmi Rẹ yoo fọwọ kan ara wọn ti o n ṣaisan. Gba bẹẹ, Oluwa. Wọn n gbadura fun ara wọn.

208 Mo si gbadura, Ọlọrun Ọwọn, wipe Ẹmi Mimọ yoo jẹ ki o da wọn loju tobẹẹ ti wọn ki yoo fi ṣe aigbagbọ mọ laelae. Aisan miran si tun wà, Oluwa, eyiti o buru pupọ ju aisan ti ara yii lọ, iyẹn ni aisan ti ẹmi. Jẹ ki gbogbo ọkan ki o ṣí.

209 Oluwa, bawo ni o ṣe jẹ wipe Iwọ duro si ibẹyẹn lẹgbẹ Abrahamu, ti Iwọ si ṣe nkan yii kannaa, O sọ fun Sarah ti o wà "lẹyin" Rẹ, Iwe Mimọ wipe, "ó rẹrin ninu àgó," Iwọ si sọ fun-un. Abrahamu si mọ wipe Ẹlohimu niyẹn, Ọlọrun nla naa. Ni iṣẹ́ju diẹ si i, Iwọ poora mọ ọ loju.

210 Ẹ̀wẹ̀, Oluwa, nigbati Jesu duro, ti O si ṣe nkan kannaa, O ni, "Ẹ pe Abrahamu ni 'baba' yin, sibẹ, ẹ sọ wipe ẹ mọ Iwe Mimọ." O ni, "Ẹ kuna, nitoripe ẹ kò mọ Iwe Mimọ tabi Agbara Ọlọrun." Wọn si pe E ni "Beelsebuubu."

211 Ṣugbọn O ṣe ileri wipe ni ikẹyin ọjọ, Iwọ yoo tú Ẹmi Rẹ jade lẹẹkan si i. Wolii naa wipe, "Ni aṣálẹ, imọlẹ yoo wà." Ibẹ ni a wa yii.

212 Nigbati aye ailofin yii n yí ninu ẹ̀ṣẹ̀, bi igbati ọmutipara bá ta gẹ́ẹ́gẹ́ẹ́ lọ si ilé ni alẹ, laipẹ, a o dana sun-un, boya ni eérú ìjóná rẹ̀ yoo fi ṣẹ́kù. A si ri i wipe akoko naa ti n sunmọ.

213 Ọlọrun o, mu gbogbo iyemeji kuro ninu wa. Mu wa lọ sinu ìpele yẹn nisisiyi. Maa bọ, Ẹmi Mimọ. Na ìyẹ́ nla Rẹ jade sita, ìji bo ijọ eniyan kekere yii nisisiyi, ki Iwọ ki o si wọ inu ọkàn wọn lọ, jẹ ki wọn mọ wipe Iwọ wà ni Iwaju Ọlọrun, wipe Iwọ ni, "Emi ni Oluwa ti o wo gbogbo àrùn rẹ sàn." Jẹ ki Ifarahan rẹ ṣe nkankan si ọkan wọn, eyiti yoo mu wọn kuro nihin yii, ni owuro yii, ki wọn si gbagbọ pẹlu ohun gbogbo ti o wa ninu wọn. Jẹ ki gbogbo awọn alaisan ati awọn ti a n da lóró gba iwosan.

214 Gẹgẹbi iranṣẹ Rẹ, mo duro, mo si fi gbogbo ẹmi èṣù bú, mo fi gbogbo aisan bú, mo fi Satani bú.

215 O ti padanu, ahalẹ lasan ni o jẹ́. A pe ọ nija ni owuro yii, ni Orukọ Jesu Kristi. Gẹgẹbi iranṣẹ Rẹ̀, ti o n waasu Ọrọ Rẹ̀, ti o si n sọ Otitọ fun awọn eniyan, wipe ki wọn ṣe ohun ti o to, ki wọn si tẹle Ọrọ Ọlọrun, mo fi ọ bu, Satani, ni Orukọ Jesu Kristi. Kuro lọdọ gbogbo awọn eniyan wọnyi, awọn ti o wá lati ibi ti o jinna, ati itosi, fun iwosan. Kuro laarin ijọ yii, ati lọdọ awọn eniyan wọnyi. Mo fi Ọlọrun alaaye fi ọ bú. Bibeli wipe, "Adura olododo n ṣiṣẹ agbara gidigidi." Ọ̀pọ̀ awọn olododo eniyan ni o gbe ọwọ wọn le awọn alaisan, nibi ni owuro yii. Ah, Satani, iwọ yoo fẹ mu wọn rò wipe emi ni, ki iwọ lee gba ògo lori wọn. Ṣugbọn igbagbọ wọn ninu Ọlọrun ni pẹlu, wọn gba Ọlọrun gbọ! Iwọ sì nilati kuro, nipa igbagbọ wọn. Nitorinaa, mu ọna rẹ pọn kuro nihin, ki o si lọ sinu okunkun biribiri, ibẹ ni aaye rẹ. Mo fi ọ bu, ni Orukọ Jesu Kristi, nipa àṣẹ Bibeli Ọlọrun, nipa iṣẹ́ ti Angẹli gbe le mi lọwọ. Njẹ nisisiyi, maa lọ, ni Orukọ Jesu Kristi, ki o si jẹ ki wọn di ominira. Amin.

216 Ṣe ẹ gbagbọ, pẹlu gbogbo ọkan yin, wipe a ti wò yín sàn? Ẹ na ọwọ yin soke, wipe, "Mo gba Jesu Kristi nisisiyi gẹgẹbi Oluwosan mi.

Gbogbo ojiji ti poora kuro lọdọ mi. Mo gba A nisisiyi ninu ẹkunrẹrẹ agbara Rẹ̀, ninu ibukun Ifarahan Rẹ̀. Mo gba A."

Igbagbọ mi n wo Ọ,
Ọd'aguntan Kalfari,
Olugbala;
Gbọ 'gba mo ba pe Ọ,
Mu ẹ̀ṣẹ̀ mi kuro,
Ma jẹ ki n ṣako lọ
Ni ọdọ Rẹ.

Ẹ jẹ ki a fi ayọ na ọwọ wa soke si I bayi.

Gba mo ba n la okunkun kọja,
Ti'ibanujẹ yi mi ka,
Ṣ'Amọna mi (Ọlọrun o);
Sọ òru mi d'ọ̀sán,
Mu'banujẹ mi lọ,
Ma jẹ ki n ṣako lọ,
Ni ọdọ Rẹ.

…oore-ọfẹ nla… 

59-0301M Híhá Ni Ẹnu Ọ̀nà Náà
Agọ́ Branham
Jeffersonville, Indiana Orilẹ-Ede Amẹrika

YORUBA

©2026 VGR, ALL RIGHTS RESERVED

Voice Of God Recordings
P.O. Box 950, Jeffersonville, Indiana 47131 U.S.A.
www.branham.org

Aṣẹ Onkọwe

Gbogbo ẹtọ́ si iwe yii jẹ ti òntẹ̀wé. A lee tẹ iwe yii lori ẹrọ-ìtẹwé abẹ́-ilé fun ìlò ara ẹni, tabi lati fi funni, lọfẹ, gẹgẹbi ohun-èlò lati tan Ihinrere Jesu Kristi kalẹ. A ko lee ta iwe yii, tabi ki a ṣe èdà rẹ ni òpòlọpọ̀, tabi ki a gbe e sori ẹrọ ayélujára, tabi ki a fi pamọ́ si ibiti a tun ti lee faa jade pada, tabi ki a tumọ rẹ si awon èdè miran, tabi ki a lo o lati fi beere fun owó, lai si ìfààyègbà ti a kọ sinu iwe lati ileiṣẹ Ohùn Ọlọrun Tí A Ká Silẹ.

Fun awọn alaye si tabi awọn ohun èlò miran, ẹ kọwe si:

VOICE OF GOD RECORDINGS
P.O. BOX 950, JEFFERSONVILLE, INDIANA 47131 U.S.A.
www.branham.org